# Awọn Obirin Ninu Islam

## Si Ọkankan Awọn Obirin Ninu Aṣa Atọwọdọwọ Juu - Kristiẹni

## Arosọ & Ododo



Dr. Sherif Abdel Azeem

www.islamic-invitation.com

# Awọn Obirin Ninu Islam

## Si Ọkankan Awọn Obirin Ninu Aṣa Atọwọdọwọ Juu - Kristiẹni

## Arosọ & Ododo

**LATI ỌWỌ: SHERIF ABDEL AZIM,**
**PH.D.- QUEENS UNIVERSITY,**
**KINGSTON, ONTARIO, CANADA**

*ITUMỌ: Hudhayfah Dhikrullah Abdus-Salaam*
*LL.B. - Al-Azhar University,*
*Cairo, Egypt*

# Awọn Ohun ti o ko Sinu

ỌRỌ ASỌṢAAJU ……………………………....................2
APA 1 - ẸBI EFA………………..………………….............5
APA 2 – OHUN TI EFA FI LELẸ ………………………7
APA 3 – AWỌN ỌMỌBIRIN ẸGAN ATI ITIJU……….11
APA 4 – ẸKỌ ỌMỌBIRIN……………………………...13
APA 5 – AWỌN OBIRIN ALAIMỌ ELEERI…………..15
APA 6 - IJẸ ẸLẸRI……………………………………...16
APA 7 – AGBERE……………………………………...18
APA 8 – AWỌN ẸJẸ……………………………………20
APA 9 - AWỌN OHUN INI IYAWO…………………...22
APA 10 - KIKỌ ARA TỌKỌ TAYA (ITU-YIGI)...........25
APA 11 - AWỌN ABIYAMỌ…………………………...32
APA 12 – OGUN OBIRIN………………………………35
APA 13 – IPO AWỌN OPO-BIRIN…………………….37
APA 14 – ILOBIRIN PUPỌ……………………………..39
APA 15 – IBORI…………………………………………46
APA 16 - ỌRỌ IPARI…………………………………...51
ỌRỌ ETI BEBE………………………………………….57

# ỌRỌ ASỌṢAAJU

Ni ọdun marun sẹhin, mo ka ninu iwe *Toronto Star* ti o jade July 3, 1990 ọrọ akọsilẹ kan ti akọle rẹ jẹ *Islam Nikan Kọni o nlo awọn Ilana Baba-Nla* lati ọwọ Gwynne Dyer. Ọrọ akọsilẹ yi ṣalaye bi awọn akopa ninu apero kan ti o da lori awọn obirin ati aṣẹ ti o waye ni Montreal ṣe fesi tibinutibinu si awọn alaye ọrọ ti gbajugbaja obirin nni ọmọ Egypt Dr. Nawal Saadawi ṣe alaye rẹ. Ninu ọrọ rẹ ti ko jẹ gbigba lawujọ ni wipe: "*a o ri awọn ohun ti o fi nha mọ awọn obirin julọ ni akọkọ ninu ẹsin Ju ninu Majẹmu Lailai lẹhinna ninu ẹsin Kristiẹniti lẹhinwagbana ninu Al-Qur'an." "gbogbo awọn ẹsin patapata ni wọn nlo baba-nla nitoripe wọn jade lati inu awọn awujọ ti ni igbagbọ ninu baba-nla,"* ati *"ibori awọn obirin ki nṣe iṣe Islam lọtọ biki nṣe aṣa ajogunba pẹlu afijọ awọn ẹsin toku."* Ara awọn akopa nibi apero yi kole gbe ijoko yi mọ nigbati awọn ẹsin wọn ti deede pẹlu Islam. Bayi, Dr. Saadawi ri awọn atako ti koṣe e rọ danu gba. *"A ko gba awọn alaye ọrọ Dr. Saadawi yi wọle. Awọn esi rẹ yi si nṣe afihan aini agbọye ti o peye nipa awọn igbagbọ awọn ẹlomiran,"* eyi ni ohun ti Bernice Dubois ti ajọ World Movement of Mothers sọ. *"Emi gbọdọ ṣe ikilọ"*, ọkan ninu awọn alakitiyan-obirin Alice Shalvi ti Israel women's network, *"kosi ero ibori ninu ẹsin Ju."* Ọrọ akọsilẹ yi ṣeṣa awọn ẹhonu ti o nipa yi gidigidi ni Iha Iwọ-Oorun lati le di ẹru ọran ẹlomiran le Islam lori fun awọn iṣe ti o jẹ diẹ ninu awọn aṣa ajogunba ti awọn ara Iha Iwọ-Oorun. Gwynne Dyer kọ bayi pe: *"Awọn alakitiyan-obirin Kristiẹni ati Juu koni joko papọ pẹlu awọn Musulumi buburu yi lati jiroro ni aaye kanna mọ,"*

Kojẹ ohun iyalẹnu funmi wipe awọn akopa nibi apero yi leni ero odi bayi si Islam, paapajulọ nigbati o ba ti ko awọn ọrọ ti o niṣe pẹlu awọn obirin sinu. Ni Iha Iwọ- Oorun, igbagbọ wọn ni wipe niti ododo Islam jẹ apẹrẹ iṣe awọn obirin ni ọmọ ẹhin. Lati le mọ ti igbagbọ yi ṣe lagbara to, o yẹ lati ṣe iranti wipe Alabojuto Ọrọ Ẹkọ ni France, the land of Voltaire, paṣẹ laipẹ lile gbogbo awọn ọmọbirin Musulumi ti wọn ba bo ori wọn kuro ni awọn ile-ẹkọ France![1]. Ọmọbirin Musulumi ti o ba lo ibori wọn di lọwọ ẹtọ ikọ ẹkọ rẹ ti o ni labẹ ofin ni France, nigbati wọn ko si kọ fun ọmọ akẹkọ Catholic ti o lo agbelebu tabi ọmọ akẹkọ Juu ti o de ate lati kọ ẹkọ. Iri bi awọn ọlọpa

agbofinro France ṣe ndi awọn ọmọbirin Musulumi ti wọn lo ibori lọna lati wọ inu ile-ẹkọ giga wọn ko le jẹ ohun igbagbe. O tun nmuwa ranti iṣẹlẹ adojutini iru bẹẹ ti Gomina George Wallace alakoso Alabama ni 1962 ti o duro ni iwaju ẹnu-ọna abawọle ile-ẹkọ ni ẹniti o ngbidanwo lati di awọn ọmọ akẹkọ ti wọn jẹ dudu lọna latile ṣọ yiya awọn ile-ẹkọ Alabama sọtọ. Iyatọ ti o wa laarin awọn iṣẹlẹ mejeeji yi ni wipe ọpọlọpọ awọn enia ni U.S ati ni gbogbo aye ni wọn ba awọn ọmọ akẹkọ dudu ṣe ikẹdun.

U.S National Guard ni Olori orilede Kennedy ranlọ lati fi ipa awọn ọmọ akẹkọ ti wọn jẹ dudu wọle. Ni apa keji ẹwẹ, awọn ọmọbirin Musulumi ko ri iranlọwọ kankan gba lati ọdọ ẹnikọkan. O jọ wipe wọn fẹ ẹ le mari ẹni bawọn kẹdun, boya nile tabi ni ẹhin odi France. Idi ni wipe itankalẹ ede aiyede ati ibẹru ohun ti ẹsin Islam jẹ ni agbaye loni.

Ohun ti mori dimu ju nipa apero Montreal naa ni ibeere kan: Njẹ ọrọ ti Saadawi, tabi eyikeyi ninu awọn alatako rẹ sọ yi ni o daju? Ni agbekalẹ gbolohun miran, Ṣe ero kanna ni ẹsin Ju, Kristiẹniti ati Islam ni nipa obirin? Njẹ wọn yatọ si ara wọn nibi awọn agbọye wọn yi? Njẹ ni otitọ ni ẹsin Ju ati Kristiẹniti fun awọn obirin ni itọju ti o peye ju bi Islam ṣe nṣe lọ? Kini o jẹ ododo gan?

Ki nṣe ohun ti o rọrun ni lati wadi ati lati wa esi fun awọn ibere ti o nira wọnyi. Ohun ti o jẹ inira alakọkọ ni wipe enia gbọdọ ṣe otitọ ki o si ma ṣe ojuṣaju tabi, bi o lewu ki o kere mọ. Eyi ni ohun ti Islam nkọ wa. Al-Qur'an ṣe idanilẹkọ fun awọn Musulumi lati ma sọ ododo koda ki awọn ti wọn jẹ alasunmọ wọn julọ ma nifẹ si eyi. *"Bi ẹ ba sọrọ ẹ ṣe dede koda bi o fẹ ki o ba olubatan yin wi"* **(Qur'an 6:152)** *"Mo pe ẹnyin onigbagbọ ododo; ẹ jẹ oluduro-ṣinṣin pẹlu ẹtọ ni ẹri-jijẹ nitori ti Ọlọhun, bi o tilẹjẹ pe o tako ẹnyin funra nyin tabi awọn obi mejeeji ati awọn olusunmọ nyin, ibajẹ ọlọrọ tabi talaka."* **(Qur'an 4:135)**

Ohun inira miran ti o tobi ni gbigbooro ti ohun ti a nsọ ọrọ le lori gbooro. Nitorinaa, ni aarin awọn ọdun diẹ sẹhin, emi lo ọpọlọpọ wakati ni ẹniti o fin ka Bibeli, ***Iwe Iwadi nipa Esin -The Encyclopaedia of Religion- ati Iwe Iwadi nipa Judaica - The Encyclopaedia of Judaica-*** ni ẹniti o nṣe iwadi fun awọn idahun/esi. Mo si ti ka ọpọlọpọ awọn iwe ti o nsọrọ nipa ipo/aaye awon obirin ninu awọn oniranran ẹsin ti awọn ọmọwe, ajafẹtọ ati awọn

alatako kọ. Ohun ti o jẹ agbekalẹ awọn ori-ọrọ ti o nbọ yi ni o nṣe afihan awọn abajade pataki ti iwadi jẹjẹ yi. Emi ko sọ wipe moja-nikoro. Nitoripe eyi kọja agbara mi ti o ni opin. Awọn ohun ti emi kan le sọ ni wipe, emi ti nṣe igbiyanju yika iwadi yi, lati le sunmọ ailẹgbẹ Al-Quran eyiti o dara julọ *isọrọ niwọtunwosi.*

Emi yio fẹ lati fi rinlẹ ninu ọrọ asọṣaaju yi wipe idi pataki mi fun afiyesi yi ki nṣe lati tabuku ẹsin Ju tabi Kristiẹni. Gẹgẹ bi awa Musulumi, a ni igbagbọ ninu awọn ipilẹ mimọ awọn mejeeji. Kosi ẹniti o le jẹ Musulumi laini igbagbọ ninu Mose ati Jesu gẹgẹ bi Awọn Anabi Ọlọhun. Ipinnu mini lati wẹ Islam mọ ati lati gbe oriyin fun Ihin Ọrọ Iye ikẹhin lati ọdọ Ọlọhun si awọn abara enia ti wọn ti nṣe ireti rẹ ni Iha Iwọ-Oorun tipẹtipẹ. Emi yio tun nifẹ bakanna lati fi rinlẹ wipe ohun ti o jẹ ogongo akolekan mi ni Ilana. Eleyi ni wipe, ogongo akolekan mi da lori ipo/aaye awọn obirin ninu awọn ẹsin mẹtẹẹta ni gẹgẹ bi o ti wa ninu awọn ipilẹ wọn ti ko si ki nṣe gẹgẹ bi awọn ẹgbẹgbẹrun ọmọ-lẹhin ṣe nṣe ni agbaye loni.

Nitorinaa, ọpọlọpọ ẹri ti mo muwa ni o jẹ lati inu Al-Qur'an, awọn ọrọ Anabi Muhammad, Bibeli, Talmud, ati ọrọ awọn Alagba pataki Ijọ awọn ti ero wọn ko ipa pataki ti o si ni apẹrẹ lara ẹsin Kristiẹniti. Eleyi nisi awọn ibi pataki ti o niṣe pẹlu idaniloju wipe ini agbọye ẹsin kan pato lati ara iṣesi ati ihuwasi awọnkan ti wọn ni orukọ lasan ninu awọn ọmọ-lẹhin iṣini lọna ni o jẹ. Ọpọlọpọ awọn enia ni wọn nṣe adapọ aṣa pẹlu ẹsin, ọpọlọpọ awọn miran ni ko mọ ohun ti iwe ẹsin wọn nsọ, ọpọlọpọ ni ko si ni akakun pẹlu.

# APA 1 - ẸBI EFA

Awọn ẹsin mẹtẹẹta papọ lori ipilẹ kan ti o fojuhan gan: Wipe Ọlọhun ni o ṣẹda awọn ọkunrin ati obirin, Ẹlẹda gbogbo aiye patapata. Ṣugbọn, gbara lẹhin iṣẹda ọkunri akọkọ; Adam, ati obirin akọkọ; Efa ni iyapa ẹnu ti bẹrẹ. Wọn ṣe alaye ero Ju - Kristiẹni lori ida ẹda Adam ati Efa ni ẹkun rẹrẹ ni inu **Gẹnẹsisi 2:4 – 3:24**. Ọlọhun kọ fun awọn mejeeji lati j eso igi ewọ. Ejo si tan Efa lati jẹ ninu rẹ, ni idakeji, Efa naa si tan Adam lati jẹ ẹ pẹlu rẹ.

Nigbati Ọlọhun ba Adam wi fun ohun ti ṣe yi, ohun naa wada gbogbo ẹbi rẹ le Efa lori, o si wi bayi pe *"Obirin ti iwọ fi pẹlu mi, on li o fun mi ninu eso igi na, emi si jẹ"* *Fun idi eyi, Ọlọhun si wi fun Efa pe: "Emi o sọ ipọnju ati ilogun rẹ di pupọ; ni ipọnju ni iwọ o ma bimọ; lọdọ ọkọ rẹ ni ifẹ rẹ yio ma fi si, on ni yio si ma ṣe olori rẹ."*
*O si wi fun Adam pe: "Nitori iwọ gba ohun aya rẹ gbọ, ti iwọ si jẹ ninu eso igi na… a fi ilẹ bu nitori rẹ; ni ipọnju ni iwọ o ma jẹ ninu rẹ li ọjọ aiye rẹ gbogbo…."*

A ri ero Islam nipa akọkọ ẹda ni ọpọlọpọ aaye ninu Al-Qur'an, fun apẹẹrẹ:
*"Atipe irẹ Adama, irẹ ati iyawo rẹ, ẹ ma gbe inu ọgba idẹra na ki ẹ si ma jẹ nibikibi ti o ba wu nyin, ki ẹ ma si sunmọ igi yi ki ẹ ma ba wa ninu awọn alabosi, Eṣu si ko royiroyi ba awọn mejeeji ki ole fihan awọn mejeeji ohun ti a bo fun wọn ni ihoho ara wọn. (Eṣu) sọ (fun wọn) pe: Oluwa ẹnyin mejeeji ko wulẹ kọ fun nyin nipa igi yi bikoṣe pe ki ẹnyin mejeeji ma ba di malaika abi ki ẹ ma ba jẹ ẹniti yio ṣe gbere nibẹ. O si bura fun awọn mejeeji pe dajudaju emi jẹ afunninimọran rere fun ẹnyin mejeeji. O si mu awọn mejeeji ṣina pẹlu itanjẹ. Nigbati awọn mejeeji tọ igi na wo, ihoho awọn mejeeji si han si wọn, nwọn si bẹrẹ si fi ninu ewe ọgba idẹra na bo ara wọn. Oluwa awọn mejeeji sipe wọn pe: nje Emi ko ti kilọ fun nyin nipa igi yi Ni, Emi si ti wi fun nyin pe dajudaju eṣu jẹ ọta ti o han gbangba fun nyin. Awọn mejeeji wipe: Oluwa wa, a ti bo ara wa si, ti o ko ba fi ori jin wa ki o si ṣe anu wa dajudaju a o jẹ ẹni-ofo."* **(Qur'an 7:19-23)**

Bibojuwo awọn agbekalẹ meji ti o da lori idẹda daradara nṣe afihan ipilẹ awọn iyapa ẹnu kan. Al-Qur'an, ni iyatọ si si Bibeli, nigbati o ngbe ẹbi kanna fun Adam ati Efa fun aṣiṣe awọn mejeeji. Kosi ibikan ninu Al-Qur'an

ti ẹnikan ti le ri tabi kofiri wipe Efa ṣe ẹtanjẹ fun Adam lati le jẹ ninu igi koda tabi wipe Efa ti jẹ ẹ ṣiwaju Adam. Ninu Al-Qur′an Efa ki nṣe atanni, arenilo ati ẹlẹtan. Jubẹẹlọ, Efa kọ ni o tọ lati gbe ẹbi fun lori awọn irora akoko ibimọ. Ni ibamu si Al-Qur'an, Ọlọhun ko ni fi iya jẹ ẹnikẹni nitori awọn aṣiṣe ẹlomiran. Ọkọọkan ninu Adam ati Efa ni o ṣẹ ẹṣẹ lẹhinna wọn si bẹ Ọlọhun fun amojukuro O si ṣe amojukuro ẹṣẹ fun awọn mejeeji.

# APA 2 – OHUN TI EFA FILẸ

Aworan Efa gẹgẹ bi ẹlẹtan ninu Bibeli lapa odi lara awọn obirin ni jakejado aṣa Juu - Kristiẹni. Wọn ni adiọkan wipe gbogbo awọn obirin patapata ni wọn ti jogun aworan –ti Bibeli gbe kalẹ fun Efa- lati ara iya wọn, ẹbi ẹṣẹ ati iwa arekereke rẹ. Fun idi eyi, gbogbo wọn ni ko ṣe gbẹkẹle, alaini iwa ọmọluwabi lara, ti wọn jẹ ẹniburuku. Wọn ka iṣe nkan oṣu, oyun nini ati inira akoko ibimọ si ijẹniya ti o yẹ fun ẹṣẹ aiyeraye awọn obirin ẹni egun. Ki a le mọ bawo ni iroyin Efa ninu Bibeli ṣe lapa sodi lori gbogbo awọn arọmdọmọbirin rẹ a gbọdọ boju wo awọn iwe awọn Ju ati Kristiẹni ti wọn jẹ danindanin ni awujọ wọn ni gbogbo asiko.

Ẹ jẹ ki a bẹrẹ pẹlu Majẹmu Lailai ki a si wo diẹ ninu ohun ti wọn npe ni *Iwe Oye 'Wisdom Literature'* ninu eyi ti a tiri: *"Mo si ri ohun ti o koro ju iku lọ, ani obirin ti aiya rẹ iṣe idẹkun ati awọn, ati ọwọ rẹ bi ọbara, ẹnikẹni ti inu Ọlọrun dun si yio bọ lọwọ rẹ, ṣugbọn ẹlẹṣẹ li a o ti ọwọ rẹ mu ..... ni wiwadi rẹ li ọkọkan lati ri oye, ti ọkan mi nwakiri sibẹ, ṣugbọn emi ko ri ọkunrin kanṣoṣo ninu ẹgbẹrun ni mo ri ṣugbọn obirin kan ninu gbogbo awọn wọnni, emi ko ri"* **(Oniwasu 7:26-28).**
Ninu apa miran ti Iwe Heberu ti wọn ri ninu Catholic Bible a ka wipe: *"Ko si iwa buburu ti o nbọ lati ibikibi ti o to iwa buburu obirin kan ..... Ẹṣẹ bẹrẹ pẹlu obirin kan nitori tirẹ gbogbo wa yio ku"* **(Oniwasu 25:19, 24).**
Rabbis ti awọn Juu to awọn egun mẹsan kan lẹsẹsẹ ti yio ma jẹ ijẹniya fun obirin latari iṣẹlẹ yi: *"O fun obirin ni egun mẹsan ati iku: ila irora ẹjẹ nkan oṣu le e lọrun ati ẹjẹ ibale; inira oyun; inira akoko ibimọ; inira itọju ọmọ ti yio fi dagba; ibo ori rẹ gẹgẹ bi ẹniti o nṣe ọfọ; yio gun eti rẹ gẹgẹ bi ẹru laiyẹsẹ tabi ẹrubirin ti nsi olowo rẹ; a o ni gbagbọ gẹgẹ eleri; ati wipe lẹhin gbogbo nkan.... Iku."*[2.]

Titi di oniyi, awọn ọkunrin Juu orthodox ma nka ninu adua owurọ ti ojojumọ wọn *"Ọpẹ fun Ọlọhun Ọba gbogbo aiye ti ko dami ni obirin."* Ni idakeji ẹwẹ, awọn obirin naa ma ndupẹ fun Ọlọhun ni gbogbo owurọ fun "*dida mi ni ibamu si ero Rẹ."*[3]

Adua miran wa ninu ọpọlọpọ awọn iwe adua awọn Juu: *"Ẹyin fun Ọlọhun lori wipe ko dami ni keferi. Ẹyin fun Ọlọhun lori wipe ko dami ni obirin. Ẹyin fun Ọlọhun lori wipe ko dami ni oponu."*[4]

Iroyin Efa ninu Bibeli ko ipa ti o tobi pupọ ninu Kristiẹniti ju ti inu ẹsin Juu lọ. Ẹṣẹ rẹ jẹ eyi ti o rọgbaka igbagbọ Kristiẹniti nitoripe ero Kristiẹni lori idi fun iran Jesu niṣẹ lori ilẹ aiye jẹ eyiti o yapa lati ara iṣe aigbọran Efa si Ọlọhun. O ti da ẹṣẹ lẹhinna o tun wa tan Adam lati tẹle ipa ẹsẹ rẹ. Nitorina, Ọlọhun wa le awọn mejeeji jade ninu ọgba Idẹra wa si orilẹ Aiye, eyiti wọn ti ge ni egun nitori wọn. Wọn fi ẹṣẹ wọn lilẹ, eleyi ti Ọlọhun ko ṣe aforijin rẹ fun wọn, fun gbogbo awọn arọmọdọmọ wọn, bayi, gbogbo enia ni a bi pẹlu ẹṣẹ lọrun. Lati le wa fọ enia mọ kuro ninu awọn 'ẹṣẹ abinibi', Ọlọhun ni lati fi Jesu rubọ, ẹniti wọn gba wipe o jẹ Ọmọ Ọlọhun, ni ori agbelebu. Nitorina, Efa nikan ni yio dahun fun aṣiṣe rẹ, ẹṣẹ ọkọ rẹ, ẹṣẹ abinibi ti gbogbo iwa enia, ati iku Ọmọ Ọlọhun. Ni agbekalẹ miran, iṣe obirin kan ti daṣe funra rẹ ni o fa iṣubu iwa enia.[5] Bawo wa niti awọn ọmọbirin rẹ? Ẹlẹṣẹ ni gbogbo wọn bi ti ẹ naa atipe bakanna ni ẹ ṣe gbọdọ ba wọn lo. Tẹti si ohun roro St. Paul ninu Majẹmu Titun: *"Jẹ ki obirin ki o maa fi idakẹjẹ ati itẹriba gbogbo kọ ẹkọ. Ṣugbọn emi kofi aṣẹ fun obirin lati ma kọni, tabi lati paṣẹ lori ọkunrin, bikoṣepe ki o dakẹjẹ. Nitori Adamu li akọda, lẹhinna Efa. Ako si tan Adamu jẹ, ṣugbọn obirin na, nigbati a tan a, o ṣubu sinu ẹṣẹ."* **(1Timoteu 2:11-14).**

Koda St. Tertullian tun fẹ kunu ju St. Paul lọ, nigbati o nba arabirin rẹ ti o nifẹsi ju sọrọ, ninu igbagbọ:[6] *"Ṣe o mọ wipe ẹnikọọkan yin Efa ni? Idajọ Ọlọhun lori ẹya obirin bi tiẹ yi nwa lori atirandiran yi: ẹbi ẹṣẹ naa gbọdọ ma wa bẹẹ. Ẹnu-ọna agbawọle lẹjẹ fun eṣu: Ẹyin ni aṣiṣọ loju igi ewọ: Ẹyin ni akọkọ ẹniti o yapa aṣẹ mimọ: Ẹyin ni ẹjẹ ẹniti o tan an ẹniti eṣu ko ni igboya ti o to lati le fi koju rẹ. Ẹ da aworan Ọlọhun ti o rọrun ju wo, ọkunrin. Lori igbọnri kuro yi koda ni Ọmọ Ọlọhun kule."*

St. Augustine jẹ olotitọ si ohun ti awọn ti o ṣiwaju rẹ fi lelẹ, o kọ iwe si ọrẹ rẹ kan: *"Kini iyatọ boya iyawo ni tabi iya, Efa kanna ni ẹlẹtan ẹniti a gbọdọ ṣọra fun lara eyikeyi obirin... Emi o ri iwulo ohun ti obirin le jẹ si ọkunrin, ti a ba yọ iwulo ibi awọn ọmọ kuro."*

Ni ọgọgọrun ọdun sehin, St. Thomas Aquinas ṣi nka obirin gẹgẹ bi nkan yẹpẹrẹ: *"Ni iwoye si adamọ nkan kọọkan, ẹniti kope ni obirin ati aṣibi pẹlu, ti nkan ti o ba jade lara ọmọkunrin bani agbara dada iru rẹ bi ọkunrin ni yio*

*mu jade; nigbati o jẹ wipe ibi ọmọbirin ma nwaye latari lilẹ ti nkan yi balẹ tabi ti nkan yi ko ba ni alafia ti o peye, tabi ti nkan miran ba lapa lara rẹ."*

Nipari, alatunṣe olokiki nni Martin Luther kori ohun ti o jẹ nkan anfani kan lati ara obirin ti o kọja wipe ima bi awọn ọmọ si aiye ni iyekiye ti o ba le bi laiwo atunbọtan rẹ: *"Ti wọn ba di alarẹ tabi ki wọn papoda, eleyi ko jẹ nkankan. Ẹ jẹ ki wọn ku si ori irọbi, ohun ti wọn wa nibẹ fun ni eyi."*
Lẹkansi ani lẹkansi, wọn ko ka obirin kun nitori aworan Efa ẹlẹtan, ọpẹ ni fun akọsilẹ ti Gẹnẹsisi ṣe. Ni aropọ gbogbo rẹ, wọn ti ba ero awọn Juu - Kristiẹni jẹ pẹlu ini igbagbọ ninu wipe Efa ati awọn arọmọdọmọ obirin rẹ ẹlẹṣẹ niwọn niti adamọ. Ti a ba dari ọkan wa nisinyi lọsi ibi awọn ohun ti Al-Qur'an ni lati sọ nipa awọn obirin, a o pada ri wipe ero Islam nipa awọn obirin yatọ gedegede si ti Juu - Kristiẹni. Jẹki Al-Qur'an sọrọ funra rẹ:

*"Dajudaju awọn ti o ju ọwọ-jusẹ silẹ fun Ọlọhun ni ọkunrin ati ni obirin, ati awọn onigbagbọ ododo ni ọkunrin ati obirin, ati awọn ti o tẹle ti (Ọlọhun) ni ọkunrin ati ni obirin, ati awọn olododo ni ọkunrin ati ni obirin, ati awọn onisuru ni ọkunrin ati ni obirin, ati awọn ti npaya Ọlọhun l'ọkunrin ati ni lobirin, ati awọn ti ntọrẹ ni ọkunrin ati ni obirin, ati awọn ti o ngbawẹ ni ọkunrin ati ni obirin, ati awọn t'onṣọ abẹ wọn l'ọkunrin ati l'obirin, ati awọn ti o nranti Ọlọhun ni ọpọlọpọ (igba) ni ọkunrin ati ni obirin, Ọlọhun ti pa lese de wọn aforiji ati ẹsan ti o tobi."* **(Qur'an 33:35).**

*"Onigbagbọ ododo ọkunrin ati onigbagbọ ododo obirin apakan wọn jẹ ọrẹ apakeji, nwọn npa iwa rere laṣẹ (fun enia) nwọn nkọ iwa buburu (fun enia) nwọn si ngbe irun duro, nwọn si nyan saka, nwọn si tẹle ti Ọlọhun ati Ojiṣẹ Rẹ. Awọn eleyi Ọlọhun yio ṣe aanu wọn, dajudaju Ọlọhun ni Alagbara Ọlọgbọn."* **(Qur'an 9:71).**

*"Oluwa wọn si jẹ ipe wọn pe: Emi ki yio pa iṣẹ oṣiṣẹ kan ninu nyin ladanu ni ọkunrin tabi obirin, apakan yin jẹ ara apakeji."* **(Qur'an 3:195)**

*"Ẹniti o ba ṣe buburu kan a ko ni san a lẹsan ayafi iru rẹ atipe ẹniti ba ṣe rere ni ọkunrin tabi obirin ti o si jẹ olugbagbọ ododo, awọn wọnyi ni yio wọ ọgba idẹra."* **(Qur'an 40:40)**

*"Ẹnikẹni ti o ba ṣe iṣẹ rere lọkunrin ati lobirin ti o si jẹ olugbagbọ ododo nitorina Awa yio jẹki o lo igbesi aiye ti o dara, dajudaju A o san wọn ni ẹsan fun eyiti o darajulọ ninu iṣẹ ti nwọn ṣe"* **(Qur'an 16:97)**

O jẹ ohun ti o foju han gedegede wipe ero Al-Qur'an nipa awọn obirin ko yatọ si eyiti o ro awọn ọkunrin. Awọn mejeeji, jẹ ẹda Ọlọhun ti o jẹ wipe idi pataki fun idawọn si aiye ni lati wa jọsin fun Oluwa wọn, iṣe awọn iṣẹ rere, kiwọn si jina si iwa aburu atipe awọn mejeeji ni wọn yio gbiwo bakanna.
Al-Qur'an ko tilẹ mu ẹnu ba rara wipe ọna agbawọle ni obirin jẹ fun eṣu tabi wipe adamọ wọn ni itanjẹ. Bakanna, Al-Qur'an ko mu ẹnu ba rara wipe aworan Ọlọhun ni ọkunrin jẹ; awọn ọkunrin ati obirin ẹda Ọlọhun ni gbogbo wọn nṣe koju bayi lọ. Ni ibamu pẹlu Al-Qur'an, ipa obirin kan lori ilẹ aiye ko mọ lori ibi ọmọ nikan. Wọn fẹ ki oun naa ṣe ọpọlọpọ iṣẹ dada gẹgẹ bi wọn ṣe fe ki ọkunrin naa ṣe e. Al-Qur'an ko sọ wipe awọn obirin ti kope niwa tiẹ wa ni aiye yi rara. Ni idajikeji, Al-Qur'an ti pa laṣẹ fun gbogbo awọn olugbagbọ, awọn obirin gẹgẹ bẹẹ naa ni ọkunrin, lati tele ipasẹ awọn obirin ti o dara julọ awọn bi Mariyama ati Iyawo Firiaona.
*"Ọlọhun sit un fi apejuwe lelẹ fun awọn onigbagbọ ododo nipa iyawo Firiaona nigbati o sọpe: Oluwa mi kọ ile kan fun mi ni ọdọ Rẹ sinu ọgba idẹra atipe ki O gbami la lọwọ Firiaona ati iṣẹ rẹ, atipe ki O gbami la lọwọ awọn ijọ alabosi. Atipe Mariyama ọmọbirin Imrana ti o ṣọ abẹ rẹ, A si fẹ (si ara rẹ) ninu ẹmi Wa, o si gba lododo ọrọ Oluwa rẹ ati awọn tira Rẹ o jẹ ọkan ninu awọn ti o tẹle aṣẹ."* **(Qur'an 66:11-12)**

# APA 3 – AWỌN ỌMỌBIRIN ẸGAN ATI ITIJU

Niti ododo, iyatọ ti o wa laarin iha ti Bibeli ati Al-Qur'an kọ si ẹya-abo nbẹrẹ nigbara lati igba ti wọn ba ti bi ọmọ obirin. Ni apejuwe, Bibelinsọ wipe asiko igba ti abiyamọ mafi nwa ni aimọ ti ẹsin njẹ ilọpo meji ni odiwọn igba ti o ba jẹ ọmọbirin ni o bi ju igba ti o ba bi ọmọkunrin lọ. **(Lẹf. 12:25)**. The Catholic Bible nsọ ni kedere wipe: *"Adanu ni ibi ọmọbirin jẹ"* **(Oniwasu 22:3)**. Ni idakeji ọrọ ti o muni wa riri yi, awọn ọmọkunrin ma ngba oriyin pataki: *"Ọkunrin kan ti o ba kọ ọmọkinrin rẹ ni ẹkọ yio jẹ ẹgan ọta rẹ*" **(Oniwasu 30:3)**.
Rabbis ti awọn Juu ṣe ni ọranyan le awọn ọkunrin Juu lori lati bi ọmọ ki iran nni le gboro si. Ni asiko kanna, wọn ko fi ifẹ wọn ti o han si awọn ọmọkunrin pamọ: *"Rere fun awọn ti o jẹ wipe awọn ọmọ wọn ọkunrin ni ṣugbọn aburu fun awọn ti o jẹ wipe awọn ọmọ wọn obirin ni"*, *"Nigbati wọn ba bi ọmọkunrin, gbogbo enia yio dunnu…. Nigbati wọn ba bi ọmọbirin, gbogbo enia yio banujẹ"*, ati *"Ni asiko ti ọmọkunrin ba nbọ wa si aiye, alafia ni o nbọ si aiye…. Ni asiko ti ọmọbirin ba nbọ wa si aiye, kosi nkankan ti o nbọwa."*[7]

Wọn ka ọmọbirin si ohun inira ti koṣe mani, orisun itiju ti o lagbara fun baba rẹ*: "Alaigbọran ni ọmọbirin rẹ? Ki o kiyesi gidigidi ki o ma ba le fi ẹ ṣe hun ẹrin awọn ọta rẹ, ọrọ ti gbogbo ara ilu yio ma sọ, ohun ofofo, ti yio wa fi ẹ sinu ojuti gbogbo enia"* **(Oniwasu 42:11)**, *"Tọju alaigbọran ọmọbirin si abẹ abojuto ti o lagbara, aijẹbẹ yio ko abuku ba eyikeyi ikẹ ti o ba nri. Fi ọwọ iṣọ ti o lagbara mu ailojuti rẹ, maṣe ṣe emọ ti o ba yẹyẹ rẹ"* **(Oniwasu 26:10-11)**.

Iru iro ihuwa si ọmọbirin gẹgẹbi ikori ojuti yi kanna ni o ṣe atọna awọn Larubawa keferi, ṣiwaju ki Islam o te de, lati ma ri awọn ọmọbirin bọlẹ ni aiye.

Al-Qur'an ṣe ibawi gidigidi fun fun iru iwa buruku yi: "*Yio ma fi ara pamọ fun awọn enia nitori buburu ohun ti a fun u niro rẹ. Yio ha mu u dani lori pe abuku ni tabi ki o ri i mọlẹ (laaye)? Ẹ gbọ o, ohun ti wọn da lẹjo ma buru o"* **(Qur'an 16:59).**

Ani lati mu ẹnu ba wipe iwa ọdaran buruku yi ko ba ma dawọ duro ni awujọ Larubawa ti ki iba nṣe ọla ohun lile ti Al-Qur'an lo lati dẹkun iwa bayi **(Qur'an 16:59, 43:17, 81:8-9)**. Siwaju si, Al-Qur'an ko ki nṣe iyatọ laarin awọn ọmọkunrin ati awọn ọmọbirin. Ni iyatọ si ohun ti o wa ninu Bibeli, Al-Qur'an ri ibi ọmọbirin gẹgẹbi ẹbun ati ọrẹ lati ọdọ Ọlọhun, bakanna ni ti o ba jẹ ọmọkunrin ni wọn bi. Koda ẹbun ọmọbirin ni Al-Qur'an kọkọ darukọ: *"Ti Ọlọhun ni ikapa sanma ati ilẹ. A ma da ohun ti O ba fẹ (ni ẹda). A ta ẹniti O ba fẹ lọrẹ ọmọbirin A si ma ta ẹniti O ba fẹ lọrẹ ọmọkunrin."* **(Qur'an 42:49)**.

Lati le dẹkun gbogbo awọn ipasẹ pipa ọmọbirin ni awujọ Musulumi ni akoko yi, Anabi Muhammad ṣe adehun ẹbun gbogi fun awọn ti Ọlọhun ba ta lọrẹ ọmọbirin ti wọn si fi ẹsẹ wọn le oju ọna ti o tọ: *"Ẹnikẹni ti o ba wa ninu awọn ti o ntọ ọmọbirin, ti o si tọ wọn daradara, wọn yio jẹ aabo fun kuro ninu Ina ọrun-apaadi"* **(Buhari ati Muslim)**, *"Ẹnikẹni ti o ba ṣe itọju awọn ọmọbirin meji titi ti wọn fi di wundia, Oun ati Emi yio wa ni ọjọ Agbende bi bayi; O pa awọn ika rẹ pọ"* **(Muslim)**.

# APA 4 – ẸKỌ OBIRIN

Iyatọ ti o wa laarin awọn ero inu Bibeli ati Al-Qur'an nipa awọn obirin ko duro lori ọmọ obirin aṣẹṣẹbi nikan, bikoṣe pe o kọja gbogbo eyi. Ẹ jẹ ki a ṣe agbeyẹwo iwa awọn mejeeji si obirin ti o ngbiyanju lati kọ ẹkọ ẹsin rẹ wo. Ọkan ẹsin Juu ni Taoreta, Ofin. Sibẹsibẹ, ni ibamu si Talmud, "wọn yọ awọn obirin sẹhin nibi ikọ nipa Taoreta". Rabbis awọn Juu kan laa lelẹ gbangba wipe *"Ẹ jẹ ki ina jo ọrọ Taoreta dipo ki ẹ fi kọ awọn obirin lẹkọ lọ"*, ati *"Ẹnikẹni ti o ba kọ ọmọbirin rẹ ni Taoreta gẹgẹbi o ṣe wa inira ni o kọ"*[8] Iṣesi St. Paul ninu Majẹmu Titun ko ki nṣe ohun ti o bamu: *"Jẹ ki awọn obirin nyin dakẹ ninu ijọ, nitori a ko fifun wọn lati sọrọ, ṣugbọn jẹ ki wọn wa labẹ igbọran, gẹgẹbi ofin pẹlu ti wi. Bi nwọn ba si fẹ kọ ohunkohun, ki nwọn ki o bere lọwọ ọkọ wọn ni ile; nitori ohun itiju ni fun awọn obirin lati ma sọrọ ninu ijọ"* **(1Kọritian 14:34-35)**.

Bawo ni obirin ṣe le kọ ẹkọ ti wọn ko ba yọnda fun lati sọrọ? Bawo ni obirin ṣe le dagba ni oye ti wọn ba ṣe ni oniranyan fun lati jupajusẹ silẹ? Bawo ni o ṣe le yanju ọrọ ara rẹ nigba ti ọna ba daru mọ loju ti orisun ifisun rẹ kanṣo si ti wa nilẹ?

Nibayi, lati ootọ, ani lati bere: Njẹ ipo Al-Qur'an jatọ bi? Itan kekere kan ti wọn sọ ninu Al-Qur'an nṣe alaye ipo rẹ ni ṣoki. *Khawlah* jẹ Musulumi obirin ti ọkọ rẹ *Aws* sọ gbolohun yi nigba ti o nbinu: "Iwọ si emi da gẹgẹbi ẹhin iya mi". Eleyi ni awọn keferi Larubawa nlo lati jẹ ọrọ ikọ obirin, gbolohun ti o ma ntu ọkọ silẹ kuro nibi nini eyikeyi ajọṣepọ lọkọlaya ṣugbọn ko fi obirin laaye ominira lati fi ile ọkọ rẹ silẹ tabi lati fẹ ọkunrin miran. Nigbati o gbọ ọrọ yi lati ọdọ ọkọ rẹ, *Khawlah* kọ ni alaafia mọ. O lọ si ọdọ Anabi Islam lati lọ ṣipẹ ọrọ rẹ. Anabi gba nimọran pe ki o ṣe suuru nigbati ko ti si ọna abayọ. *Khawlah* ṣi nṣe fanfa pẹlu Anabi ni ẹniti o ngbidanwo lati yọ ninu ewu igbeyawo rẹ ti wọn pati. Laipẹ, Al-Qur'an dasi; ipẹ *Khawlah* di gbigba. Idajọ Ọlọhun pa aṣa aiṣe deede yi run. Odidi Ọgba-Ọrọ kan (Ọgba-Ọrọ 58) Al-Qur'an ti akọle rẹ jẹ *"Alimujadilah"* eyini *"Obirin ti o nṣipẹ"* ni wọn sọ orukọ rẹ lẹhin iṣẹlẹ yi:

*"Dajudaju Ọlọhun ti gbọ ọrọ (obirin) eyiti on ba ẹ ṣe ariyanjiyan nipa ọkọ rẹ o si o si nke ibosi lọsi ọdọ Ọlọhun; atipe Ọlọhun si ngbọ tamioromi ẹnyin mejeeji. Dajudaju Ọlọhun ni Olugbọrọ, Ariran..."* **(Qur'an 58:1)**

Ninu agboye Al-Qur'an obirin ni ẹtọ lati ṣe ariyanjiyan koda pẹlu Anabi Islam funrarẹ. Kosi ẹniti o ni ẹtọ lati paṣẹ fun pe ki o dakẹ. Ko si ni abẹ ide kan lati sọ pe ọkọ rẹ nikan ni abi ohun nikan lo gbọdọ ma juwe rẹ sọna nibi awọn ikan ofin ati ẹsin.

# APA 5 - AWỌN OBIRIN ALAIMỌ ELEERI?

Awọn ofin ati awọn ilana Juu ti o da lori awọn obirin ti nṣe nkan oṣu jẹ eyi ti wọn paala rẹ gidigidi. Majẹmu Lailai ka obirin ti onṣe nkan oṣu si alaimọ ati eleri. Jubẹlọ, aimọ rẹ yi ma "nran" awọn ẹlomiran bakanna. Ẹnikẹni tabi ohunkohun ti o ba fi ọwọ kan yio di alaimọ fun odidi ọjọ kan: *"Bi obirin kan ba si ni isun, ti isun rẹ li ara rẹ ba jasi ẹjẹ, ki a ya sapakan ni ijọ meje: ẹnikẹni ti o ba si fi ara kan a, ki o jẹ alaimọ titi di aṣalẹ. Ati ohun gbogbo ti o dubule lẹ ninu ile iyasapakan rẹ yio jẹ aimọ. Ati ẹnikẹni ti o ba farakan akete rẹ ninu omi, ki o si jẹ alaimọ titi di aṣalẹ"* **(Lẹf. 15:19-23)**.

Nitori adamọ *"ẹgbin"* rẹ yi, obirin ti o nṣe nkan oṣu rẹ lọwọ jẹ *"ẹniti wọn ma nya aye rẹ sọtọ"* nigbamiran lati le kọdi ini ohunkohun ṣe pẹlu rẹ. Wọn yio fi si ile ọtọ kan ti wọn npe ni *"ile ẹlẹgbin"* fun gbogbo asiko aimọ rẹ.[9] Talmud nri obirin ti o nṣe nkan oṣu ni irisi *"apani"* koda laisi ifaragbọnra pẹlu rẹ: *"Rabbis wa kọwa pe: ...ti obirin ti nṣe nkan oṣu ba kọja laarin ẹnimeji (awọn ọkunrin), ti o ba jẹ ibẹrẹ oṣu rẹ ni yio pa ikan ninu awọn mejeeji, ti o ba jẹ igbẹhin nkan oṣu rẹ ni yio da ija si aarin awọn mejeeji"* **(bPes. 111a)**.

Siwaju si, wọn ṣe ni ewọ fun ọkọ obirin ti o nṣe nkan oṣu rẹ lọwọ lati wọ synagogue ti o ba jẹ wipe obirin yi ti sọ ohun na di alaimọ koda ki o kan jẹ pẹlu biba gbọn erukun danu ni abẹ atẹlẹsẹ rẹ. Alufaa ti iyawo, ọmọbirin, tabi iya rẹ ba nṣe nkan oṣu ko le ka adua alufaa ninu synagogue.[10] Abajọ ti awọn obirin Juu fi nri iṣe nkan oṣu gẹgẹbi *"egun"*[11].

Islam o ri obirin ti o nṣe nkan oṣu rẹ bi ẹniti o ni "iwa eleri" kankan lara rara". Ko ki nṣe "ẹniti a ko gbọdọ fi ara kan" bẹsini ki nṣe "ẹni egun". O nṣe igbesi aiye rẹ bi o titọ ṣugbọn pẹlu aala kanṣoṣo: Wọn ko yọnda fun tọkọtaya lati ni ajọṣepọ ni asiko ti o nṣe nkan oṣu lọwọ. Wọn yọnda fun wọn lati ṣe awọn ajọṣepọ miran ti o ku. Wọn yọ obirin ti o nṣe nkan oṣu lọwọ kuro ninu awọn ti awọn iṣẹ ijọsin kan jẹ ọranyan fun bi awọn irun ojoojumọ ati awẹ gbigba.

## APA 6 - IJẸ ẸLẸRI?

Ijiyan miran ninu eyiti Al-Qur'an ati Bibeli nyapa ẹnu le lori ni ijiyan lori ki awọn obirin ṣe ẹlẹri. Otitọ ni wipe Al-Qur'an ti kọ awọn olugbagbọ ododo ti wọn nṣe owo/karakara lẹkọ lati ni ẹlẹri ọkunrin meji tabi ọkunrin kan ati obirin meji **(Qur'an 2:282)**. Sibẹsibẹ, bakanna ọtitọ ni wipe Al-Qur'an ni igba miran ma ngba ẹri obiran kan bi ti ọkunrin kan. Ni tootọ ẹri obirin kan le la ẹri ọkunrin kan mọlẹ nigba miran. Ti ọkunrin kan ba fi ẹsun aimọ kan iyawo rẹ, Al-Qur'an fẹ ki o bura atinuwa ni igba marun ni ẹri wipe iyawo rẹ jẹbi ẹsun ti o fi kan. Ti iyawo ba tako ti ohun naa si bura bakanna ni igba marun, wọn ko gba wipe o jẹbi, eyikeyi ti owu ki o le jẹ wọn ka igbeyawo wọn yi si eyi ti o ti tuka. **(Qur'an 24:6-11)**.
Ni ida keji, wọn ko yọnda fun awọn obirin lati jẹri ni awujọ awọn Juu akọkọ.[12] Rabbis fi ailejẹri awọn obirin si aarin awọn egun mẹsan ti wọn fi awọn obirin gun nitori Ifasẹhin (bojuwo apa *"Ohun ti Efa fi lelẹ"*). Wọn ko yọnda fun awọn obirin ni Israẹli ti ode oni lati jẹri ni awọn ile-ẹjọ Rabbis.[13] Awọn Rabbis da kini idi ti awọn obirin ko fi le jẹri ni ile-ẹjọ lare pẹlu mimu **Gẹnẹsisi 18:9-16** wa lẹri, ti o wa nibẹ pe Sara, iyawo Abrahamu parọ. Awọn Rabbis ma nlo iṣẹlẹ yi gẹgẹbi ẹri wipe awọn obirin ko kun oju oṣuwọn lati jẹ ẹri. A gbọdọ ṣe akiyesi ni ibiyi wipe itan ti wọn sọ ninu **Gẹnẹsisi 18:9-16** yi wọn muwa ninu Al-Qur'an ni eyiti o ju igba kanṣo lọ laisi ofiri wipe Sara pa irọ **(Qur'an 11:69-74, 51:24-30)**. Ninu Kristiẹni ti iha Iwọ-Oorun, awọn ofin mejeeji ti alufaa ati ti ara ilu ni o kọ fun awọn lati jẹri titi di ọwọ igbẹhin sẹntiuri ti o gbẹhin.[14]

Ti ọkunrin kan ba fi ẹsun iwa aimọ kan iyawo rẹ, ni ibamu si Bibeli wọn ko ni gba ijẹrisi rẹ -iyawo- wọle rara. Iyawo ti wọn fi ẹsun kan gbọdọ jẹjọ pẹlu idanwo. Ninu ipelẹjọ yi, iyawo nkoju adanwo ati itẹniloriba ti ilana ẹsin eleyi ti o gbọdọ fi idi ijẹbi tabi aimọkan rẹ mulẹ **(Numeri 5:11-13)**. Lẹhin idanwo yi ti wọn bari wipe o jẹbi, wọn yio da ẹjọ iku fun. Ti ko ba jẹbi, ọkọ rẹ koni jẹbi ẹsun eyikeyi aṣiṣe.

Jubẹẹlọ, ti ọkunrin kan ba mu obirin kan bi iyawo lẹhinna owa fi ẹsun kan wipe ki nṣe wundia, wọn koni gba ijẹrisi tiẹ -iyawo- wọle rara. Awọn obi rẹ ni o gbọdọ mu ẹri ti fi nrilẹ wipe wundia ni wa niwaju awọn agba ilu. Ti awọn obi ko ba le fi idi aimọkan ọmọ wọn rilẹ, wọn yio lẹ loko pa siwaju

ẹnu ọna baba rẹ. Ti awọn obi ba wa le fi idi aimọkan rẹ mulẹ, wọn yio ni ki ọkọ san ẹsan itanran ọgọrun kan ṣekeli ti fadaka lasan ko si ni le kọ iyawo rẹ silẹ ni odiun igbati o ba ṣi wa laiye:

*“Bi ọkunrin kan bag be iyawo kan, ti o wọle tọ ọ, ti o si korira rẹ, Ti o si ka ọran si lọrun, ti o siba orukọ rẹ jẹ, ti o si wipe, Mo gbe obirin yi,nigbati mo si wọle tọ ọ, emi ko ba a niwundia: Nigbana ni ki baba ọmọbirin na, ati iya rẹ, ki o mu ami wundia ọmọbirin na tọ awọn agba ilu lọ li ẹnubode: ki baba ọmọbirin na ki o si wi fun awọn agba na pe, Emi fi ọmọbirin mi fun ọkunrin yi li aya, o si korira rẹ. Si kiyesi i, o si ka ọran si i lọrun, wipe, Emi ko ba ọmọbirin rẹ niwundia; bẹẹni wọnyi ni ami wundia ọmọbirin mi. Ki nwọn ki o sina aṣọ na niwaju awọn agba lu. Ki awọn agba ilu na ki o si mu ọkunrin na, ki nwọn ki o sin a a, ki nwọn ki bu ọgọrun ṣekeli fadaka fun u, ki nwọn ki o si fi fun baba ọmọbirin na, nitoriti o ba orukọ wundia kan ni Israeli jẹ, ki on ki o si maa ṣe aya rẹ, ki o ma ṣe kọ ọ li ọjọ aiye rẹ gbogbo. Ṣugbọn bi ohun na ba ṣe otitọ,ti a ko ba si ri ami wundia ọmọbirin na, Nigbana ni ki nwọn mu ọmọbirin na wa si ẹnu-ọna ile baba rẹ, ki awọn ọkunrin ilu rẹ ki o sọ ọ li okuta pa, nitoriti o hu ibi ni Israeli, ni ṣiṣe agbere ninu ile baba rẹ: bẹẹni ki iwọ ki o mu iwa buburu kuro laarin nyin”* **(Deuteronomi 22:13-21)**.

## APA 7 – AGBERE?

Gbogbo ẹsin ni wọn ri iwa agbere si iru ofin Ọlọhun. Bibeli gbe idajọ iku kalẹ ni ofin fun ọkọọkan awọn alagbere ọkunrin ati alagbere obirin. **(Lefitiku 20:1)**. Bakanna ni Islam jẹ ọkọọkan awọn alagbere ọkunrin ati alagbere obirin niya **(Qur'an 24:2)**. Ṣugbọn, itumọ ti Al-Qur'an tu agbere si yatọ gedengbe si itumọ ti Bibeli tumọ rẹ si. Agbere, ni ibamu si Al-Qur'an, jẹ ibalopọ lọkọlaya ti ki nṣe ọna ẹtọ ti o waiye laarin ọkunrin ti o ti ni iyawo ati obirin ti o ti ni ọkọ. Obirin ti o ti ni ọkọ ti o tun wa ni ibalopọ lọkọlaya ti ki nṣe ọna ẹtọ pẹlu ẹlomiran ni Bibeli ka kun iwa agbere **(Lefitiku 20:10, Deuteronomi 22:22, Awọn Owe 6:20, 7:27)**.

*"Bi a bamu ọkunrin kan ti o ba obirin kan dapọ, ti a gbe ni iyawo fun ọkọ, njẹ ki awọn mejeeji ki o ku, ati ọkunrin ti o ba obirin na dapọ, ati obirin na; bẹẹni ki iwọ ki o si mu ibi kuro ni Israeli"* **(Deut. 22:22)**.

*"Ọkunrin ti o ba ba aya ọkunrin miran ṣe panṣaga, ani on ti o ba aya ẹnikeji rẹ ṣe panṣaga, panṣanga ọkunrin ati panṣaga obirin li a o pa li tootọ"* **(Lef. 20:10)**.

Ni ibamu si alaye inu Bibeli, ti ọkunrin ti o ti ni iyawo ba ṣe panṣaga pẹlu obirin ti ko ti ni ọkọ, wọn ko ka eleyi kun ọran rara. Ọkunrin ti o ti ni iyawo ti o tun wa ni ibalopọ ti ko lẹtọ pẹlu awọn obirin ti ko ni ọkọ ki nṣe alagbere ọkunrin bẹẹna ni awọn obirin ti ko ti ni ọkọ ti o ni ibalopọ pẹlu rẹ ki nṣe alagbere obirin. Ida ẹṣẹ agbere ma nṣẹlẹ nikan nigbati ọkunrin kan, yala o ti ni iyawo tabi apọn, ṣe panṣaga pẹlu obirin adelebọ kan. Nibayi, wọn ka ọkunrin kun alagbere, koda ki o jẹ apọn, wọn si ka obirin pẹlu si alagbere. Ni kukuru, panṣaga ni eyikeyi ibalopọ ti o lodi si ofin pẹlu obirin adelebọ. Ini ibalopọ ni ọna aitọ ti ọkunrin ti o ti ni iyawo ko ki nṣe ẹṣẹ pato ninu Bibeli. Kiwa ni idi ti awọn mejeeji ko fi ri bakanna ni iṣe? Ni ibamu si Encyclopedia Judaica, wọn ka iyawo kun ohun ini ọkọ ni eyiti panṣaga si jẹ ohun ti o nko ipalara ba ẹtọ ọkọ ti o ni lori rẹ; iyawo si niyi gẹgẹbi ohun ini ọkọ ko ni iru ẹtọ bayi lori rẹ.[15] Eyini wipe, ti ọkunrin kan bani ibalopọ

lọkọlaya pẹlu obirin adelebọ kan, yio ma jẹ ipalara fun ohun ẹtọ ọkunrin miran, ti o ba ri bẹẹ, wọn gbọdọ jẹ ẹ niya.

Titi di oniyi ni Israel, ti ọkunrin ti o ti ni iyawo bani ibalopọ ti ko tọ pẹlu obirin wundia kan, awọn pẹlu obirin yi jẹ ọmọ ẹtọ. Ṣugbọn, ti obirin adelebọ bani ibalopọ pẹlu ọkunrin miran, boya o ti ni iyawo tabi koni iyawo, awọn ọmọ rẹ pẹlu ọkunrin naa ki nṣe ọmọ aitọ nikan ṣugbọn ọmọ-ale niwọn pẹlu bakanna ni o jẹ ewọ fun wọn lati awọn Juu miran ayafi awọn ti o gba ẹsin ati awọn ọmọ-ale miran. Ifofin de yi wa de ori awọn arọmọdọmọ wọn de awọn iran mẹwa titi di igba ti o sunmọ ki abuku agbere naa ti lẹ.[16]

Ni apakeji, Al-Qur'an ko ka eyikeyi obirin lati jẹ ohun ini ọkunrin kankan. Al-Qur'an fi laakaye gbe alaye ajọṣepọ ti o wa laarin ọkọ ati iyawo kalẹ ni ẹniti o nsọ bayi:

*"Atipe o mbẹ ninu ami Rẹ pe, O da awọn aya fun nyin lati ara nyin ki ẹ le ba ma ri ifaiyabalẹ lọdọ wọn, O si ṣe ifẹ ati ikẹ si aarin nyin. Dajudaju awọn ami mbẹ ninu eyi fun awọn enia ti o nronu"* **(Qur'an 30:21)**.

Eyi ni ero ti Al-Quran nipa igbeyawo: ifẹ, anu, ati isimi, ki nṣe ohun ini ati ajulọ.

# APA 8 – AWỌN ẸJẸ?

Ni ibamu si Bibeli, ọkunrin gbọdọ mu ẹjẹ ti o ba da si Ọlọhun ṣẹ, ko si gbọdọ ge adehun rẹ. Ni ida keji, wọn ko jẹ obirin nipa lati mu ẹjẹ rẹ ṣẹ. Baba rẹ gbọdọ fi ọwọ si i, ti o ba jẹ wipe o ṣi ngbe ni ilẹ rẹ, tabi ki ọkọ rẹ fi ọwọ si ti o ba jẹ wipe o ti ni ọkọ. Ti baba/ọkọ ko ba fi ọwọ si awọn ẹjẹ ọmọbirin/iyawo rẹ, asan ati ofo ni gbogbo awọn ohun ẹjẹ ti o da:

*"Ṣugbọn bi baba rẹ ba kọ fun u li ọjọ na ti o gbọ, ko si ọkan ninu ẹjẹ rẹ, tabi ninu ide ti o fi de ara rẹ ti yio duro.... ṣugbọn bi ọkọ rẹ ba kọ fun u li ọjọ na ti o gbọ, njẹ on o mu ẹjẹ rẹ ti o jẹ ati ohun ti o ti ẹnu rẹ jade, eyi ti o fi de ara rẹ, dasan"* **(Num. 30:2-15)**.

Kini idi rẹ ti o fi jẹ pe ẹjẹ kan ki nṣe ọranyan papa? Idahun si eleyi jẹ eyi ti o rọrun: nitoripe baba rẹ ni o ni i, ṣiwaju igbeyawo, tabi ọkọ rẹ ni o ni i, ni ẹhin igbeyawo rẹ. Agbara bari ọmọbirin nipa debi wipe, o le gbiro lati ta a! Wọn tọka si ninu iwe awọn Rabbi wipe: *"Ọkunrin kan le ta ọmọbirin rẹ, ṣugbọn obirin ko le ta ọmọbirin rẹ; ọkunrin le fi ọmọbirin rẹ fọkọ, ṣugbọn obirin ko le fi ọmọbirin rẹ fọkọ."*[17] Iwe awọn Rabbi tun ntọka si wipe igbeyawo nduro fun igbe ini agbara lori ọmọbirin kuro ni ọdọ baba lọsi ọdọ ọkọ: *"ifọmọfọkọ, nsọ obirin di ohun ini –ohun ini alailebajẹ- ti ọkọ..."* Ohun ti o han ni, ti wọn ba ka obirin si ohun ini ẹnikan, ko le mu ẹjẹ ti olowo rẹ ko ba fi ọwọ si ṣẹ.

O jẹ ohun ti odun mọni lati ṣe akiyesi wipe ẹkọ Bibeli ti o da lori ijẹ ẹjẹ awọn obirin yi lapa sodi lori awọn obirin Juu - Kristiẹni titi di ibẹrẹ senturi yi. Obirin kan ti o ba ni ọkọ ni Iha Iwọ-Oorun aiye ko ni ipo labẹ ofin. Kosi ohunkohun ti o le ṣe ti o ni iyi labẹ ofin. Ọkọ rẹ le kọ eyikeyi agbaṣe, idunadura, tabi idawọle ti o ba ṣilẹ. Awọn obirin ni Iha Iwọ-Oorun (awọn ti wọn ntele ilana Juu - Kristiẹni julọ) wọn fọn mọwọn lati ma le gbe iṣẹ fun ẹlomiran nitoripe ẹnikan ni o niwọn. Awọn obirin Iwọ-Oorun ti wa ninu inira fun nkan bi ẹgbẹrun meji ọdun nitori ọna ti Bibeli gba ri ipo awọn obirin siti awọn baba ati awọn ọkọ wọn.[18]

Ninu Islam, ẹjẹ gbogbo Musulumi, akọ tabi abo, ni o jẹ ọranyan le lori. Kosi ẹniti o ni agbara lati kọ awọn ẹjẹ ti elomiran ba jẹ.

Ikuna lati mu adehun ti ọkunrin tabi obirin ba ṣe ṣẹ, o gbọdọ jẹ eyiti yio tanran rẹ gẹgẹbi wọn ti tọkasi ninu Al-Qur'an:

*"Ọlọhun ki yio mu nyin ba wi fun ara ti ẹ bu niti ere, ṣugbọn On yio mu nyin fun ara ti ẹ finufẹdọ bu, nitorina itanran rẹ ni bibọ talika mẹwa yo ninu onjẹ ti o daraju ti ẹ nfun awọn enia nyin jẹ, tabi wiwọ wọn laṣọ tabi ki ẹ sọ ẹru kan di ọmọ, ẹniti ko ba ri* (nkankan ninu ohun wọnyi) *awẹ gbigba ọjọ mẹta* (lokan)*, eyiyi ni itanran ibura nyin nigbati ẹ ba ti bura, ẹ ma mu ibura nyin ṣẹ, bayi ni Ọlọhun nṣe alaye awọn ọrọ Rẹ ki ẹ le ma dupẹ"* **(Qur'an 5:89).**

Awọn ẹmẹwa Anabi Muhammad, lọkunrin ati lobirin, ni wọn ma nṣe ibura itele/igba ni Olori fun U tikalararẹ. Awọn obirin gẹgẹ bẹẹ na ni awọn ọkunrin, ni wọn ma wa nba funra wọn ti wọn si nda majẹmu wọn:

*"Irẹ Anabi, nigbati awọn onigbagbọ ododo obirin ba wa ba ọ ti nwọn wa ba ọ ṣe majẹmu lori pe awọn ko ni da nkan pọ mọ Ọlọhun mọ atipe awọn ko ni jale atipe awọn ko ni ṣe agbere atipe awọn ko ni pa awọn ọmọ wọn atipe awọn ko ni da adapa irọ eyiti nwọn fi ọwọ ati ẹsẹ wọn ṣe (nipa gbigbe ọmọ ti ki iṣe ti ọkọ fun u) ti nwọn ko si ni yapa rẹ nibi daradara, nigbana ba wọn ṣe majẹmu, ki o si tọrọ aforiji lọdọ Ọlọhun fun wọn. Dajudaju Ọlọhun ni Alaforiji, Onikẹ"* **(Qur'an 60:12)**.

Ọkunrin kan ko le da ẹjẹ dipo ọmọbirin tabi aya rẹ. Bẹ ẹ naa ni ọkunrin kan ko le da ẹjẹ ti ẹnikẹni ninu awọn alasunmi mọ rẹ jẹ duro.

# APA 9 – AWỌN OHUN INI IYAWO?

Awọn ẹsin mẹtẹẹta ni wọn jọ ni igbagbọ ti ko yisẹ ninu pataki igbeyawo ati igbesi aiye mọlẹbi. Bakanna ni wọn tun fi ẹnuko lori ijẹ olori ọkọ ninu ẹbi. Biotilẹwu kori, awọn iyatọ ti o fi oju han gedegbe wa laarin awọn ẹsin mẹtẹẹta ni ibamu si fi fifi aala si iṣedari. Ofin atọwọdọwọ Juu-Kristiẹni, ko da gẹgẹbi ofin Islam, ni eyiti o ngbooro ijẹ oludari ọkọ lori iyawo rẹ de ijẹ olowo iyawo rẹ.

Ofin Juu ti o niṣe pẹlu ipa ọkọ lori iyawo rẹ jẹ eyiti o nyapa lati ara ero wipe ohun ni o ni o ni i gẹgẹbi o ti ṣe ni ẹru rẹ.[19] Ero yi ni o jẹ idi ti o wa ni abẹ ṣiṣe ojumeji nibi awọn ofin agbere ati nibi agbara ọkọ ladi da majẹmu ti iyawo rẹ ṣe nu. Ero yi bakanna ni o wa nidi kikọ inikapa fun obirin lori dukia rẹ tabi awọn ohun ini rẹ. Ni gbara ti obirin Juu ba ti ni ọkọ, ni yio ti ṣe afẹku eyikeyi ikapa lori dikia ait awọn ohun ini rẹ. Awọn Rabbi ti awọn Juu fi ẹtọ ọkọ lori dukia iyawo rẹ rinlẹ gẹgẹbi wipe ohun ni o ni: *"Ni odiwun igba ti ọkunrin kan ba ti ni obirin kan njẹ tele eleyi wipe ohun naa ni yio di ẹniti o ni dukia rẹ pẹlu?"*, ati *"Ni odiwun igba ti o ba ti ni obirin njẹ koni ni ohun ini rẹ pẹlu?"*[20] Bayi, igbeyawo ma nsọ obirin ti o lọrọ di alaini rara. Talmud nṣe alaye ipo inawo iyawo gẹgẹbi o ti nbọ yi:

*"Bawo ni obirin kan ṣe ni nkan kan: ohunkohun ti o jẹ tirẹ njẹ ti ọkọ rẹ? Ohun ti o ba jẹ tirẹ -ọkọ- njẹ tirẹ -ọkọ-, ohun ti o ba jẹ -iyawo- jẹ tirẹ -ọkọ- bakanna.... Awọn ohun ini rẹ ati ohun ti o ba ri ni opopo tirẹ -ọkọ- ni bakanna. Awọn ohun elo inu ile, koda awọn ẹrunrun akara ti o wa ni ori tabili, tirẹ ni. Ti o b ape alejo wale rẹ ti o si fun ni onjẹ, a jẹ wipe o ji ninu ohun ini ọkọ rẹ..."* **(San. 71a, Git.62a)**.

Ododo ti o wa labẹ ọrọ yi ni wipe dukia obirin Juu wa lati ma fi ṣe awọn ọkunrin ti o ba wu u lati fẹ ni ojulọyin. Mọlẹbi Juu yio ya apakan ninu ohun ini baba rẹ si ọtọ fun ọmọbirin wọn nitori asiko igbeyawo lati lo o gẹgẹbi owo ori iyawo. Owo ori iyawo yi ni o sọ awọn ọmọbirin Juu di nkan iniri fun awọn baba wọn. Baba ni lati re ọmọbirin rẹ fun ọpọlọpọ ọdun lẹhinna yio wa ṣe ipalẹmọ fun igbeyawo rẹ pẹlu ipese owo ori iyawo ti o tobi silẹ.

Bayi, gbese ni ọmọbirin jẹ ninu mọlẹbi Juu ki nṣe anfani.[21] Idahun fun yi ni o nṣe alaye idi ti bibi ọmọbirin ko fi nṣe ohun idunnu ni awujọ Juu atijọ (Wo Apa Awọn *"Ọmọbirin Ẹgan ati Itiju?"*). Owo ori iyawo ni ẹbun igbeyawo ti wọn fun ọkọ iyawo ni abẹ ala iyalegbe fun akoko kan. Ọkọ yio ma ṣe gẹgẹbi wipe nkan ini rẹ ṣugbọn ko gbọdọ ta a. Iyawo yio padanu iṣe akoso lori owo ori iyawo ni akoko igbeyawo. Jubẹlọ, Wọn ni afojusọna ki o ṣiṣẹ ni ẹhin igbeyawo gbogbo ohun ti o ba si nri yio ma jẹ ti ọkọ rẹ niti owo ọya fun amojuto rẹ ti o jẹ ojuṣe rẹ. O le ri dukia rẹ gba pada ni odiwun igba meji pere: itu yigi tabi lẹhin iku ọkọ rẹ. Ti o ba jẹ wipe ohun –iyawo- ni o kọkọ ku, ọkọ ni yio jogun dukia rẹ. Ti o ba jẹ ọkọ rẹ loku, iyawo yio gba dukia rẹ ti o san ni asiko igbeyawo pada ṣugbọn koni ẹtọ lati jogun ipin kankan ninu dukia ọkọ rẹ ti o ku. Bakanna wọn gbọdọ fi kun wipe ọkọ iyawo ni lati fun iyawo rẹ ni ẹbun iyawo, pẹlu bẹẹna ohun -ọkọ- naa ni yio duro gẹgẹbi ẹniti o ni i ni odiwun igbati wọn nfẹ ara wọn.[22]

Titi di aipẹ yi, Kristiẹniti ni o ntẹle ofin atọwọdọwọ ikanna ti Juu. Awọn ẹsin mejeeji ati awọn alakiso ilu ni Christian Roman Empire (lẹhin Constantine) beere fun ifẹnuko lori dukia ni iwakani fun imọ riri igbeyawo. Awọn mọlẹbi ti o ba fi ọmọbirin wọn fun ọkọ owo ori iyawo wọn ma nbi si, fun idi eyi, wọn ma nrọ awọn ọkunrin lati tete ṣe igbeyawo ni kiakia nigbati awọn mọlẹbi si ma nsun awọn igbeyawo ọmọbirin wọn siwaju tayọ asiko ti o jẹ aṣa.[23] Ni abẹ ofin Canon, iyawo ni ẹtọ lati beere fun owo ori rẹ ti igbeyawo ba di ofo ayafi ti o ba jẹ wipe o jẹbi iwa agbere loku. Ti o baribẹ, yio padanu ẹtọ rẹ ninu owo ori iyawo eleyi ti o ku ni ọwọ ọkọ rẹ.[24] Ni abẹ ofin Canon ati ofin ara ilu obirin ti o ba ni ọkọ ni Christian Europe ati America ti padanu awọn ẹtọ rẹ lori dukia rẹ titi di igbẹhin sẹnturi ikọkandilogun ati ibẹrẹ sẹnturi ogun. Fun apẹẹrẹ, awọn ẹtọ awọn obirin ni abẹ ofin English jẹ eyiti wọn kojọ ti wọn si tẹ jade ni 1632.Ohun ti o wa ninu awọn ẹtọ yi ni: *"Ohunkohun ti ọkọ bani bani ohun ni o ni i. Ohunkohun ti iyawo bani ti ọkọ ni nṣe."*[25] Ki nṣe wipe obirin yio padanu awọn nkan ini rẹ nikan nitori igbeyawo, bikoṣe pe yio tun padanu ijẹ enia pẹlu. Ko si ohunkohun ti o le ṣe ti yio jẹ ẹtọ labẹ ofin. Ọkọ rẹ le kọ ohunkohun ti o bata tabi fi tọrẹ silẹ nitori ko si ofin kankan ti o gbe e lẹsẹ. Ẹniti o ba ni adehun pẹlu rẹ wọn ka si ọdaran nitori ikopa rẹ ninu iwa jibiti.Jubẹẹlọ, ko le pe enia lẹjọ tabi ki wọn pe lẹjọ ni orukọ tirẹ gangan, bẹni ko si le pe ọkọ rẹ lẹjọ.[26]

Wọn ma nba obirin ti o ti ni ọkọ lo gẹgẹbi ọmọde ni oju ofin. Obirin jẹ ohun ini fun ọkọ rẹ nitorina o ṣe ippadanu ohun ini rẹ, ẹtọ ijẹ enia rẹ, ati orukọ ẹbi rẹ.[27]

Islam, lati ọgọrun ọdun meje C.E, ti fun obirin ti o ba ni ọkọ -adelebọ- ni ominira ti ara rẹ eleyi ti Juu-Kristiẹni Iwọ-Oorun ko fun wọn titi di aipẹ yi. Ninu Islam, iyawo ati ẹbi rẹ ko si ni abẹ ide biotiwu ki o ri pe ki wọn fun ọkọ ni ẹbun. Ọmọbirin ki nṣe gbese ninu ẹbi Musulumi. Islam ṣe obirin ni ẹni ọwọ ni eyiti ki nṣe iwọ rẹ lati gbe ẹbun kalẹ lati fi fa oju awọn ọkunrin mọra. Ọkọ ni o gbọdọ fun iyawo ni ẹbun igbeyawo. Wọn si ka ẹbun yi kun dukia rẹ atipe ko si eyikeyi ninu ọkọ tabi ẹbi iyawo ti o ni ipin kankan ninu rẹ tabi ikapa lori rẹ. Ni awọn awujọ kan loni, ẹbun igbeyawo ti o jẹ ẹgbẹrun lọna ọgọrun dollar ni fadaka ki nṣe nkan ti oju ko riri.[28] Iyawo ni o ni ẹbun igbeyawo koda ti ọkọ rẹ ba kọ silẹ ni ọjọ iwaju. Wọn ko yọnda ipin kankan fun ọkọ ninu dukia iyawo rẹ ayafi eyiti o ba fun pẹlu ifẹ inu rẹ.[29] Al-Qur'an ti ṣe alaye ipo rẹ ni eyiti o fi o fi oju han gedegbe nipa ọrọ yi:

*"Ẹ fun awọn obirin ni owo-ifẹ wọn ni tọkantọkan, ṣugbọn bi nwọn ba fi inudidun yọnda nkankan ninu rẹ fun nyin funra wọn, nigbana ẹ jẹ ẹ pẹlu irọrun ati adun"* **(Qur'an 4:4).**

Dukia ati awọn ohun ini iyawo wa ni abẹ aṣẹ rẹ ati fun lilo rẹ nikan ni igbati o si jẹ pe abojuto ohun ati awọn ọmọ rẹ jẹ iwọ lori ọkọ rẹ.[30] Laini boju wo eyikeyi ọla ti o wu ki iyawo ni, ko jẹ ọranyan fun lati pa ọwọ pọ pẹlu ọkọ lati wa jijẹ mimu fun ẹbi ayafi ti o ba finufẹdọ yan lati ṣe eyi. Awọn ololufẹ njogun ara wọn. Jubẹ ẹ lọ, obirin adelebọ ninu Islam ṣini ominira ti ara rẹ labẹ ofin bakanna orukọ mọlẹbi rẹ.[31] Adajọ kan ọmọ America sọrọ nigbakan lori awọn ẹtọ awọn obirin Musulumi nigbati o nsọ bayi: *"Ọmọbirin Musulumi kan le ṣe igbeyawo nigba mẹwa, ṣugbọn awọn oniranran ọkọ yi ko le pa ijẹẹni tirẹ run. Irawọ ti nyi oorun ka ni ti o si ni orukọ ati ẹtọ ti o jẹ tiẹ labẹ ofin."*[32]

# APA 10 – KIKỌ ARA TỌKỌTAYA (ITU-YIGI)?

Awọn ẹsin mẹtẹẹta ni o ni awọn ijiyan alarambara nibi awọn iwo wọn nipa kikọra tọkọtaya. Gbogbo oniran ituka laarin tọkọtaya ni Kristiẹniti kọ lapapọ. Majẹmu Titun duro ṣiṣin lori wipe agbeyawo jẹ ohun ti ko ṣe tuka. Wọn ni Jesu sọ wipe: *"Ṣugbọn emi wi fun nyin, Ẹnikẹni ti o ba kọ aya rẹ silẹ, bikoṣe nitori agbere, o mu ṣe panṣaga: ẹnikẹni ti o ba si gbe ẹniti a kọ silẹ ni iyawo o ṣe panṣaga"* **(Matteu 5:32)**. Apẹrẹ alailẹgbẹ ki ko pari yi, laisi iye meji, ki nṣe otitọ.O dawọle iwa alailabawọn eleyi ti awọn awujọ enia ko ti riṣe pari. Nigbati ololufẹ meji kan ba ri wipe igbesi aiye lọkọlaya wọn ti kọja atunṣe, ifagile opiya laarin wọn ko le ṣe wọn lore kankan. Ijẹ ololufẹ meji ti ajọṣepọ wọn ko gun rege mọ nipa lati wa papọ jẹ eyiti ko wulo bẹẹni ko si ni itumọ. Abajọ ti apapọ agbaiye Kristiẹni fi nṣe igbesẹ lati ṣe ijẹwọsi kikọ ara tọkọtaya.

Ni ida keji, ẹsin Juu fayegba itu yigi koda laini idi kan pato. Majẹmu Lailai fun ọkọ ni ẹtọ lati kọ iyawo rẹ koda ko jẹ pe o kan korira rẹ lasan:

*"Bi ọkunrin kan ba fẹ obirin kan, ti o si gbe e niyawo, yio si ṣe, bi obirin na ko ba ri ojurere li oju ọkunrin na, nitoriti o ri ohun alebu kan lara rẹ, njẹ ki o kọ iwe ikọsilẹ fun obirin na, ki o fi i le e lọwọ, ki o ran a jade kuro ninu ile rẹ,. Nigbati on ba si jade kuro ninu ile rẹ, on le lọ, ki o maa ṣe aya ọkunrin miran. Bi ọkọ rẹ ikẹhin ba si korira rẹ, ti o si kọ iwe ikọsilẹ fun u, ti o si fi i le e lọwọ, ti o si ran jade kuro ninu ile rẹ; tabi ti ọkọ ikẹhin ti o fẹ ẹ li aya ba baku, ọkọ rẹ iṣaju, ti o ran jade kuro, ki o maṣe tun ni i li aya lẹhin igba ti o ti di ẹni-ibajẹ tan"* **(Deut.24:1-4)**.

Awọn ẹsẹ ti o wa loke yi ti da ariyanjiyan ti o lami silẹ laarin awọn ọjọgbọn Juu nitori iyapa ẹnu wọn lori itumọ awọn gbolohun *"airi ojurere"*, *"alebu"* ati *"ikorira"* ti wọn mu ẹnu ba ninu awọn ẹsẹ yi. Talmud kọ awọn oniranran ero wọn kalẹ:

*"Ajọ Shammai duro lori wipe ọkunrin kan ko gbọdọ kọ iyawo rẹ silẹ ayabi ti o ba ri wipe o jẹbi awọn ibalopọ pẹlu ọkunrin miran eyi ti ko tọ, nigbati ajọ*

*Hillel sọ wipe o le kọ ọ silẹ koda ki o kan ṣeṣi ba awo rẹ jẹ lasan. Rabbi Akiba sọ pe o le kọ silẹ koda ki o jẹ wipe o kan ri obirin miran ti o rẹwa ju u lọ"* **(Gittin 90a-b)**.

Majẹmu Titun nduro lori ero awọn Shammai nigbati ofin Juu duro lori ipinnu awọn Hillel ati R. Akiba.[33] Lopin igbati o jẹ wipe ero awọn Hillel ni o bori, o ti di aṣa ofin Juu ti koṣe foju rena lati yọnda fun ọkọ lati kọ iyawo rẹ laini okunfa kankan rara. Majẹmu Lailai ko fun ọkọ ni ẹtọ kikọ iyawo ti ko ri *"ojurere"* rẹ nikan bikoṣepe o ka ikọ *"iyawo buruku"* si ohun ọranyan:

*"Iyawo buruku kan ma nfa irẹnisilẹ, ifoju abuku woni, ati ọgbẹ ọkan. Ọlẹ ọwọ ati ailera orunkun ni ti ọkunrin eyiti iyawo rẹ kuna lati mu inu rẹ dun. Obirin ni orisun iru ofin Ọlọhun, atipe lati ipa ẹsẹ rẹ ni a o ku. Maṣe fi agba ti o njomi silẹ ki o kan omi tabi gba iyawo buruku laye lati sọ ohun ti o wun u. Ti ko ba tẹle aṣẹ rẹ, kọ ọ silẹ ki osi le e jade"* **(Oniwasu 25:25).**

Talmud ti ka oniranran awọn iwa kan lati ọwọ awọn iyawo eleyi ti o fi o sọ di ọranyan fun ọkọ lati kọ wọn silẹ: *"Ti o ba jẹun ni opopo, ti o ba mu ohun mimu pẹlu ojukokoro ni ita, ti o ba fi ọmu fun ọmọ ni gbangba, ni eyikeyi ti o wu kole jẹ Rabb Meir sọ wipe o gbọdọ fi ọkọ rẹ silẹ"* **(Git. 89a)**.

Talmud tun ṣe ni ofin lati le iyawo agan (obirin ti ko bimọ kankan ni iwọn ọdun mẹwa) jade: *"Awọn Rabbi wa kọwa: Ti ọkunrin kan ba fẹ aya kan ti o si gbe pẹlu rẹ fun ọdun mẹwa ti ko si bi ọmọ rara, ki o kọ ọ silẹ"* **(Yeb. 64a)**.

Ni ida keji, awọn iyawo ko le kọ ọkọ ni abẹ ofin Juu. Ṣugbọn, iyawo Juu kan, le beere fun ẹtọ lati kọ ọkọ rẹ niwaju ile-ẹjọ Juu nigbati o ba mu idi ti o fi ẹsẹ mulẹ wa. Awọn aaye diẹ ti o kere gidi ni wọn fun iyawo lati le ṣe ibeere fun fun itu yigi. Awọn aaye yi ni: Ọkọ ti o ni alebu tabi awọn arun ara, ọkọ ti ko pe awọn iwọ asopọ pẹlu iyawo rẹ, *etc*. Ile-ẹjọ legbe lẹhin ibeere iyawo ti o fẹ kọ ọkọ rẹ ṣugbọn ko le e tu igbeyawọ yi. Ọkọ nikan ni o le tu igbeyawo pẹlu ifun iyawo rẹ ni iwe ikọsilẹ. Ile-ẹjọ le jẹ ọkọ nipa, ni ki o san itanran, ti i mọle, ati ya aaye rẹ sọtọ lati jẹ ẹ nipa ki o le pese iwe ikọnisilẹ ti o pọndandan fun iyawo rẹ. Ṣugbọn ti ọkọ bay a abori kunkun ẹda, o le kọ jalẹ lati kọ iyawo rẹ ti yio si jẹ ki o ma wa pẹlu rẹ titilai. Eyiti o wa buruju, o le kọ ọ silẹ laijawe fun ti yio si fi silẹ laijẹ abi ilemọsun. O

(ọkọ) le fẹ iyawo miran tabi koda ṣe aiye pẹlu eyikeyi wọndia ti yio si bi awọn ọmọ fun (ọmọ ẹtọ ni awọn ọmọ yi ni abẹ ofin Juu).

Ni ida keji, iyawo ti wọn kọ silẹ, ko le fẹ ọkunrin miran ni odiwọn igba ti o jẹ wipe igbeyawo rẹ ti o ṣe ṣi tọ labẹ ofin bẹẹna ni ko si le gbe pẹlu ọkunrin miran ti o yatọ si ọkọ rẹ nitori pe wọn yio ka a kun aṣẹwo atipe awọn ọm ti o ba bi lati ara igbepọ yi yio ma jẹ ọmọ ale titi de ori iran kẹwa. Obirin ti o ba wa ni iru ipo bayi wọn ma npe ni agunah (obirin ti o wa ni abẹ ide).[34] Ni orile-ede America loni nkan bi 1000 si 1500 awọn obirin Juu ti wọn agunot (agunah ti o ju ẹyọkan lọ) ni o wa, nigbati onkan wọn ni Israel le jẹ bi 16000. Awọn ọkọ le fi ọna eru gba ẹgbẹẹgbẹrun dollar lọwọ awọn iyawo ti o ha siwọn lọwọ fun paṣiparọ itu yigi labẹ ofin Juu.[35]

Islam wa lagbedemeji ni aarin Kristiẹniti ati ọmọlẹhin Juda nipa itu yigi. Igeyawo ninu Islam jẹ asopọ mimọ kan ti ko gbọdọ ja ayafi pẹlu awọn idi ti o pọn dandan. Wọn paṣẹ fun awọn ololufẹ mejeeji lati ṣan gbogbo awọn ọna iwatunṣe ni gbogbo igbati igbeyawo wọn ba nwa ninu ewu.

Itu yigi kọni o gbọdọ jẹ ọna abayọ ayafi nigbati ko ba si ọna abayọ miran. Ni kukuru, Islam mọ itu yigi, pẹlu bẹ ẹ iṣe ni o nṣe aigbaniyanju rẹ pẹlu gbogbo ọna. Ẹ jẹ ki a wo iha ikọsi rẹ ni akọkọ. Islam fun awọn ololufẹ mejeeji ni ẹtọ lati fi opin si ajọṣepọ tọkọataya wọn.

Islam nfun ọkọ ni ẹtọ fun Talaq (ikọsilẹ/itu yigi).Jubẹlọ, ko ṣe bi ẹsin ọmọlẹhin Juda, nfyun iyawo ni ẹtọ lati tu igbeyawo latipasẹ ohun ti a mọ si Khul'a.[36] Ti ọkọ batu igbeyawo pẹlu ikọ iyawo rẹ silẹ, ko le gba eyikeyi ninu awọn ẹbun igbeyawo ti o fun u (iyawo) pada. Al-Qur'an nda awọn ọkọ ti wọn nkọ awọn iyawo wọn silẹ lẹkun nibi gbigb awọn ẹbun igbeyawo wọn pada bi o tilewu ki ẹbun na lowolori tabi pataki to:

*"Bi ẹnyin ba si fẹ fi iyawo kan parọ si aye iyawo kan ti ẹ si ti fun ọkan ninu wọn ni ọpọlọpọ ọrọ; ki ẹ maṣe gba nkọkan (pada) ninu rẹ, Ẹ o ha gba a niti adapa irọ (ibanujẹ) ati niti ẹṣẹ ti o han gbangba?"* **(Qur'an 4:20)**.

Ti o ba jẹ pe iyawo ni o yan lati fi opin si igbeyawo, o (iyawo) le da awọn ẹbun igbeyawo pada fun ọkọ rẹ. Ida awọn ẹbun pada ni iru aye bayi jẹ ẹsan atunṣe fun ọkọ ti o wiwa pẹlu iyawo rẹ ni okukundun nigbati ohun(iyawo) si yan lati fi silẹ.

Al-Qur'an jẹ awọn ọkunrin Musulumi nipa wipe wọn ko gbọdọ gba eyikeyi pada ninu awọn ẹbun ti wọn fit a awọn iyawo wọn lọrẹ ayafi nigba ti o ba jẹ iyawo ni yan lati tu igbeyawo:

*"Ko si tọ fun nyin pe ki ẹ gba nkankan (pada) ninu ohun ti ẹ fun wọn, ayafi ti awọn mejeeji ba mbẹru pe wọn ko ni le duro ni ẹnu-aala Ọlọhun. Bi ẹnyin na (alatunṣe) ba mbẹru pe awọn mejeeji ko ni le duro ni ẹnu-aala Ọlọhun nigbana ko si ibawi fun awọn mejeeji nipa ohun ti (aya) ba fi ṣe irapada ara rẹ. Awọn wọnyi ni awọn ẹnu-aala Ọlọhun, ẹ ma ṣe re-kọja wọn"* **(Qur'an 2:229).**

Bakanna, obirin kan wa ba Anabi Muhammad ni ẹniti o nbeere fun itu igbeyawo rẹ, o sọ fun Anabi wipe ohun ko ri ẹsun kankan ti o tako awọn iwa tabi iṣesi ọkọ rẹ. Ohun iṣoro kanṣoṣo ti obirin kan ni pẹlu ọkọ rẹ ni wipe nitootọ ko ni ifẹ mọ debi wipe ko ni ikapa lati gbe pẹlu rẹ m rara. Anabi si beere lọwọ rẹ*:*

*("Njẹ iwọ yio da ọgba rẹ (ẹbun igbeyawo ti o ti fun iwọ) pada?" obirin na si sọ wipe: "Bẹẹni". Anabi wa kọ ọkunrin yi ni ẹkọ wipe ki o gba ọgba rẹ pada ki o si tun tẹwọgba itu yigi)* **(Bukhari)**.

Ni awọn aye kan, iyawo Musulumi le ma gbiro lati tọju igbeyawo rẹ ṣugbọn ti o ba ara rẹ ni ẹniti o tọ lati beere fun ikọsilẹ nitoti awọn idi kan ti o nsọ di dandan gẹgẹbi: Aini aanu ọkọ, ipaniti lainidi, ọkọ ti ko pe awọn iwọ ajọṣepọ, *etc*. Ni awọn aye wọnyi ile-ẹjọ Musulumi ma ntu yigi.[37]

Ni kukuru, Islam fun obirin Musulumi ni awọn ẹtọ ti ko lẹgbẹ: O le fi opin si igbeyawo latipasẹ Khul'a, o sit un le bẹbẹ fun ikọsilẹ. Iyawo Musulumi ko le di ẹniti a de mọlẹ lailai pẹlu igbẹgbọnri ọkọ kan. Awọn ẹtọ wọnyi ni o ṣe awọn obirin Juu ti wọn ngbe ni awọn awujọ Islam akọkọ ti ọgọrun meje ọdun C.E. ni ojulọyin lati beere fun iri awọn iwe ikọsilẹ gba ni ọwọ awọn

ọkọ wọn Juu ni ile-ẹjọ Musulumi. Awọn Rabbi tẹnumọ wipe awọn iwe yi jẹ asan ati afo. Lati le mu opin ba igbesẹ yi, awọn Rabbi fun awọn obirin Juu ni awọn ẹtọ ati anfani titun ninu awọn igbidawo lati ko irẹwẹsi ba afilọ ti awọn ile-ẹjọ Musulumi. Wọn ko fun awọn obirin Juu ti wọn ngbe ni orilẹ-ede Kristiẹni ni eyikeyi iru awọn anfani yi ni igbati o jẹ pe ofin ikọsilẹ ti Romu nlo nibẹ ko wuni lori ju ofin Juu lọ.[38]

Nibayi, ẹ jẹ ki a bojuwa wo bi Islam ṣe nko irẹwẹsi ba itu yigi. Anabi ti Islam sọ fun awọn onigbagbọ ododo wipe: "ninu gbogbo awọn ohun ti wọn yọọda patapata, ikọsilẹ ni eyiti Ọlọhun korira julọ" (Abu Dawood).

Ọkunrin Musulumi ko gbọdọ kọ iyawo rẹ silẹ nitoripe o kan korira rẹ lasan. Al-Qur'an nkọ awọn ọkunrin Musulumi lẹkọ lati jẹ oninu rere si awọn iyawo wọn koda ni awọn asiko ibinu ati inifura ikorira:

*"Ki ẹ si ma ba wọn lo pẹlu daradara. Bi ẹ ba korira wọn, o le jẹ pe ẹ kọ ohun kan ti Ọlọhun si ti ṣe ọpọlọpọ rere sinu rẹ"* **(Qur'an 4:19)**.

Anabi Muhammad pa iru aṣẹ bayi naa:
*"Ọkunrin ti o ba jẹ onigbagbọ ododo ko gbọdọ korira obirin onigbagbọ ododo. Ti o ba korira ọkan ninu awọn iwa rẹ omiran yio si jẹ eti ti o tẹlọrun"* **(Muslim)**.

Anabi tun tẹnumọ bakanna wipe awọn Musulumi ti o darajulọ ni awọn ti wọn dara si awọn iyawo wọn:
*"Awọn onigbagbọ ododo ti wọn fi igbagbọ ti o pe han ni awọn ti o ṣe wipe wọn ni iwa daradara atipe awọn ti o dara ninu yin ni awọn ti wọn dara si awọn iyawo wọn"* **(Tirmidhi)**.

Sibẹsibẹ, Islam jẹ ẹsin ti wulo ti o si mọ wipe awọn asiko kan wa ti o jẹ wipe igbeyawo ti wa ni etibebe iparun. Ni iru awọn aaye bayi, kiki imọran iwa daada tabi idara ẹni lẹkun ko le yanju rẹ. Bayi, kini ohun ti enia le ṣe gba igbeyawo yi la kuro ninu ewu yi? Al-Qur'an nfun ọkọ tabi iyawo eyiti ẹnikeji rẹ (iyawo tabi ọkọ) jẹ oluṣe buburu ni imọran ti o wulo. Fun ọkọ ti o jẹ wipe iwa buburu iyawo rẹ ndẹruba igbeyawo yi, Al-Qur'an nmu oriṣiriṣi imọran mẹrin wa gẹgẹbi o ti ṣe alaye ninu awọn ẹsẹ ti o nbọ wọnyi:

*“Ati awọn ti ẹ nbẹru ṣiṣe orikunkun wọn, (1)ẹ ṣe kilọkilọ fun wọn, (2)ẹ takete si ibusun wọn, (3)ki ẹ si lu wọn; ṣugbọn bi nwọn ba tẹriba fun nyin njẹ ẹ ko gbọdọ wa ọna (ija) pẹlu wọn, dajudaju Ọlọhun jẹ Ọba-giga, Olutobi. (4)Bi ẹ ba si fura airẹpọ larin awọn mejeeji, ẹ yan ọlọgbọn kan ninu awọn enia ọkọ ati ọlọgbọn kan ninu awọn enia aya, bi awọn mejeeji ni kongẹ larin wọn, dajudaju Ọlọhun jẹ Olumọ, Alakiyesi”* **(Qur’an 4:34-35)**.

Mẹta alakọkọ ni wọn gbọdọ kọkọ ṣe igbiyanju rẹ. Ti o ba wa kuna, lẹhinna iranlọwọ awọn mọlẹbi ni ki enia wa beere fun. A ni lati ṣe akiyesi, nibi itan-mọlẹ si awọn ẹsẹ ti o wa loke yi, wipe lilu iyawo onitẹnbẹlẹkun jẹ iwọn diẹ nibi o ti ṣe wa ni ipo ẹlẹẹkẹta ti wọn le gunle ti a ba ni erongba wipe ohun nikan naa ni o le jẹ ọna abayọ fun iwa buburu iyawo. Ti o ba wulo, wọn ko fi aaye gba ọkọ ni gbogbo ọna ki o ma ba iyawo rẹ ja lọ gẹgẹbi wọn ti ṣe rẹ gedegbe ninu ẹsẹ yi. Ti ko ba wulo, wọn ko fi aaye gba ọkọ bakanna ki o ṣi ma lo ọna yi mọ nibayi ọna igbẹhin ti o gbọdọ gunle ni ṣiṣe pẹlu iranlọwọ awọn mọlẹbi.

Anabi Muhammad ti kọ awọn ọkọ Musulumi wipe wọn gbọdọ pada si iru awọn ọna wọnyi ayafi ni awọn aaye ti o ba pọn dandan gẹgẹbi iwa-itiju gbangba ti iyawo hu. Koda ni awọn aaye yi ijiya yi gbọdọ jẹ diẹ ati nigba ti iyawo ba taku, wọn ko yọọda fun ọkọ ki o mu u binu:
*“Ti wọn ba jẹbi iwakiwa ẹ le fiwọn sile ni awọn nikan ni ori ibusun wọn ki ẹ si fi iya diẹ jẹwọn. Ti wọn ba tẹriba fun yin, ẹ ma ṣe wa eyikeyi ọna ti ẹ le fi bawọn ja”* **(Tirmidhi)**.

Pẹlupẹlu, Anabi Islam da awọn eyikeyi lilu ọna aitọ. Awọn iyawọ Musulumi kan rojọ fun U wipe awọn wọn lu wọn. Nigbati o gbọ eleyi, Anabi ṣe alaye lẹsẹsẹ wipe:

*“Awọn ti o nṣe eleyi (lu awọn iyawo wọn) ki nṣe ẹni rere ni aarin yin”* **(Abu Dawood)**.

A gbọdọ ranti ni aaye yi wipe Anabi tun sọ pe:
*“Ẹnirere ninu yin ni ẹniti o jẹ rere si ẹbi rẹ, Emi ni mo si jẹ ẹni rere julọ laarin yin si ẹbi mi”* **(Tirmidhi)**.

Anabi gba obirin Musulumi kan ni imọran, ti orukọ rẹ njẹ Fatimah bint Qais, pe ki o ma fẹ ọkunrin kan nitoripe wọn mọ ọkunrin yi si ẹniti o ma nlu awọn obirin:

*"Emi lọ ba Anabi ni ẹniti o sọ wipe: Abu Jahm ati Mu'awiah da ẹnu ifẹ kọmi. Anabi (ni ọna imọran) sọpe: Nipa Mu'awiah o jẹ oloṣi gidi ati nipa Abu Jahm ohun ti o ba saba ni lilu awọn obirin"* **(Muslim)**.

A gbọdọ ni lọkan wipe Talmud nyọọda lilu iyawo ni ibaniwi fun ikọnilẹkọ.[39] Wọn ko fi aala si asiko ti o pọn dandan gẹgẹbi awọn iwa itiju gbangba. Wọn yọọda fun lati lu iyawo rẹ koda ki o jẹ wipe o kan kọ lati ṣe iṣẹ rẹ ninu ile. Jubẹlọ, wọn ko da lori ki o rọra bawi diẹ. Wọn gba laye ki o gba orikunkun kuro lọwọ iyawo rẹ pẹlu ki o fi panṣa na tabi ki o fi ebi pa.[40]

Fun iyawo ti o jẹ pe aiṣe deede ọkọ rẹ ni o jẹ okunfa isunmọ iforiṣọnpọn igbeyawo, Al-Qur'an ngba ni awọn imọran ti o nbọ yi:

*"Bi obirin kan ba bẹru ilokulo lati ọdọ ọkọ rẹ tabi iṣẹri-ipati, ko si ibawi fun awọn mejeeji bi nwọn ba le ṣe atunṣe larin wọn. Atunṣe ni o si dara julọ"* **(Qur'an 4:128)**.

Ni bayi, wọn gba iyawo ni imọran ki o beere fun atunṣe pẹlu ọkọ rẹ (pẹlu tabi laisi iranlọwọ mọlẹbi). O jẹ ohun akiyesi wipe Al-Qur'an ko gba iyawo nimọran ki o gba awọn ọna meji ti itakete nibi ibalopọ ati lilu. Idi fun eleyi le jẹ wipe lati daabo bo iyawo kuro nibi ipada ṣe ika lati ọdọ ọkọ rẹ eleyi ti o nṣi iwahu lọwọ. Ipalara ti ilo agbara bayi yio ṣe fun iyawo ati igbeyawo yio ju daada ti yio ṣe lọ. Awọn ọjọgbọn Musulumi kan ti daba wipe ile-ẹjọ le lo awọn ọna wọnyi lori ọkọ ni aaye iyawo. Eleyi ni wipe, ile-ẹjọ yio yio kọkọ ṣe ikilọ fun ọkọ ọlọtẹ, lẹhinna, yio kọ ibusun iyawo rẹ fun, lakotan yio lu ni lilu ti o ni apẹẹrẹ.[41]

Ni ipari rẹ, Islam gba awọn ololufẹ Musulumi ti wọn ti fẹ ara wọn ni imọran ti o ni agbara lati le yọ awọn igbeyawo ninu ewu laasigbo ati inufu-ẹdọfu. Ti ọkan ninu awọn ololufẹ meji ba nwu asop-mimọ lewu, Al-Qur'an gba ẹnikeji niyanju lati ṣe ohunkohun ti o ba rọrun ti o si lapa lati la asopọ-mimọ yi kuro ninu ewu. Ti gbobgo awọn ọna ba kuna, Islam yọọda fun awọn alajọṣepọ lati pin-ya nirọrun ati nipẹlẹ.

# APA 11 – AWỌN ABIYAMỌ?

Ni ọpọlọpọ aaye ni Majẹmu Lailai ti paṣẹ ṣiṣe daradara ati ṣiṣe abojuto awọn obi bakanna ni o sibu ẹnu atẹ lu awọn ti ko ṣe apọnle wọn. Fun apẹẹrẹ: *"Ẹnikẹni ti o ba fi baba tabi iya rẹ re, pipa li a o pa a"* **(Lef. 20:9)** ati *"Ọlọgbọn ọmọ ṣe ayọ baba; ṣugbọn aṣiwere enia gan iya rẹ"* **(Awọn Owe 15;20)**.

Bi o tilẹ jẹpe ibuyin fun baba nikan ni wọn mu ẹnu ba ni awọn ibikan, e.g. *"Ọlọgbọn ọmọ gba ẹkọ baba rẹ"* **(Awọn Owe 13:1)**, nigbati wọn kosi damu ẹnu ba iya nikan rara. Jubẹlọ, ko si itẹnumọ ọtọ nipa iṣetọju iya daradara ni apẹẹrẹ fun imọriri inira nla ti o ri ni asiko irọbi ati ifọmọ lọyan. Pẹlupẹlu, kosi ogun kankan ti awọn iya yio jẹ ninu dukia ọmọ wọn nigbati awọn baba si njẹ.[42]

O jẹ ohun ti o nira lati sọrọ Majẹmu Titun gẹgẹbi iwe mimọ ti o npepe fun ibọwọ fun iya. Yatọ si eyi, o gba ero wipe Majẹmu Titun nri iṣetọju awọn iya ni ọna ti o dara gẹgẹbi idilọwọ ni oju ọna Ọlọhun. Ni ibamu si Majẹmu Titun, ẹnikẹni ko le di Kristiẹni gidi ti o yẹ lati di ọmọlẹhin Kristi ayafi ti o ba korira iya rẹ. Wọn ni Jesu sọ wipe:

*"Bi ẹnikan ba tọ mi wa, ti ko si korira baba rẹ, ati iya rẹ, ati aya ati ọmọ, ati arakunrin ati arabirin, ani ati ẹmi ara rẹ pẹlu, ko le ṣe ọmọ-ẹhin mi"* **(Luku 14:26)**.

Pẹlupẹlu, Majẹmu Titun nroyin Jesu gẹgẹbi alainaani, tabi koda alaibọwọ fun iya rẹ. Ni apejuwe, nigbati o (iya) de ni ẹniti o nwa ti ohun (Jesu) si nṣe waasu fun akojọ awọn enia kan, ko tilẹ bikita lati jade lati lọ wo o:

*"Nigbana li awọn arakunrin rẹ ati iya rẹ wa, nwọn duro lode, nwọn si ranṣẹ si I, nwọn npe e. Awọn ọpọ enia si joko lọdọ rẹ, nwọn si wi fun u pe, Wo o, iya rẹ ati arakunrin rẹ nwa ọ lode. O si da wọn lohun, wipe, Tani iṣe iya mi, tabi awọn arakunrin mi? O si wo gbogbo awọn ti o joko lọdọ rẹ yika, o si wipe, Wo iya mi ati awọn arakunrin mi: Nitori ẹnikẹni ti o ba ṣe ifẹ Ọlọrun, on na li arakunrin, ati arabirin mi, ati iya mi"* **(Marku 3:31-35)**.

Ẹnikan le ma jiyan wipe Jesu ngbiyanju lati kọ awọn enia ni ẹkọ paaki wipe asopọ ko kere nipa ju asopọ ẹbi lọ. Sibẹsibẹ, o le kọ awọn olutẹtisi ni iru ẹkọ yi laini ṣe afihan ainaani bayi si iya rẹ. Iwa aibọwọfunni kanna yi ni o hu nigbati o kọ jalẹ lati fi ọwọ si ọrọ kan ti awọn kan ninu awọn olutẹtisi sọ ni ibukun fun ipa iya rẹ nipa ibi rẹ ati itọju rẹ:

*"O si ṣe, bi o ti nsọ nkan wọnyi, obirin kan nahun ninu ijọ, o si wi fun u pe, Ibukun ni fun inu ti o biọ, ati ọmu ti iwọ mu. Ṣugbọn on wipe, Nitootọ, ki a kuku wipe, Ibukun ni fun awọn ti ngbọ ọrọ Ọlọrun, ti wọn si pa a mọ"* **(Luku 11:27-28)**.

Ti wọn bale hu iru iwa aifinipeni bayi si abiyamọ kan ti o jẹ Wundia Maria,bi wọn ti ṣe royin rẹ ninu Majẹmu Titun, lati ọdọ ọmọkunrin kan bi Jesu Kristi, tobaribẹ bawo wa ni ki ọgọọrọ ọmọkunrin Kristiẹni ṣe huwa si awọn abiyamọ Kristiẹni?

Ninu ẹsin Islam, iyi, apọnle ati inaani ti wọn gbe fun fun awọn abiyamọ ko lẹgbẹ. Al-Quran gbe pataki ihuwa rere si awọn obi si ipo keji si ijọsin fun Ọlọhun Alagbara:

*"Atipe Oluwa rẹ palaṣẹ pe: Ẹ ko gbọdọ sin kinikan ayafi On nikan ati ki ẹ ma ṣe rere fun awọn obi mejeeji. Bi okan ninu wọn ba dagba si ọ lọwọ abi awọn mejeeji, o ko gbọdọ ṣe ṣiọ wọn bẹ si ni o ko gbọdọ jagbe mọ wọn, ṣugbọn ki o ma ba wọn sọrọ alapọnle. Ati ki o rẹ ara rẹ nilẹ fun wọn niti anu ati ki o ma sọpe: Oluwa, (ba mi) kẹ awọn mejeeji gẹgẹbi nwọn ti re (kẹ) mi ni kekere"* **(Qur'an 17:23-24)**.

Ni ọpọlọpọ awọn aaye miran ni Al-Qur'an ti ntẹnumọ ipa titobi ti iya ko ni nipa ibimọ ati itọju ọmọ:

*"Atipe awa sọ asọtẹlẹ fun enia nipa obi rẹ, iya rẹ gbe e (ninu oyun) pẹlu ailera lori ailera atipe jija ọm rẹ gba ọdun meji, pe: Dupẹ fun Mi ati fun awọn obi rẹ mejeeji. Ọdọ Mi ni ipadasi"* **(Qur'an 31:14)**.

Anabi ti ṣe alaye ipo pataki awọn iya ninu Islam yekeyeke:

*"Ọkunrin kan beere lọwọ Anabi: 'Tani ki nbu ọwọ fun julọ?' Anabi si dahun pe: 'Iya rẹ.' 'Tani o tun tẹle?' ọkunrin naa tun beere. Anabi si dahun pe: 'Iya rẹ.' 'Tani o tun tẹle?' ọkunrin naa tun beere. Anabi si dahun pe: 'Iya rẹ!' 'Tani o tun tẹle?' ọkunrin naa tun beere. Anabi dahun pe: 'Baba rẹ'"* **(Bukhari ati Muslim)**.

Diẹ ninu awọn asọtẹlẹ Islam ti o jẹ wipe awọn Musulumi ṣi nṣakiyesi rẹ niti ododo titi di oni yi ni itọju awọn iya nibi o titọ ati bi o tiyẹ. Apọnle ti awọn iya Musulumi nrigba lati ọdọ awọn ọmọkunrin ati awọn ọmọbirin wọn jẹ apejuwe gidi. Awọn ajọṣepọ ti o munadoko ti o wa laarin awọn iya Musulumi ati awọn ọmọ wọn pẹlu ibọwọfun ti o de ogongo eyiti awọn ọkunrin Musulumi nfun awọn iya wọn jẹ eyiti o ma nya awọn ara Iha Iwọ-Oorun lẹnu.[43]

# APA 12 – OGUN OBIRIN?

Ọkan pataki ninu awọn aidọgba ti o wa laarin Al-Qur'an ati Bibeli ni iha ti wọn kọ si ijẹ ogun obirin ninu dukia ẹbi ti o ku. Iha ti Bibeli kọ si jẹ eyiti Rabbi (Olukọni) Epstein se apejuwe rẹ: *"Ofin atọwọdọwọ lailai ti ko si yi pada lati igba aiye Bibeli ko fun awọn obirin idile, iyawo ati ọmọbirin ni ẹtọ ogun kankan ninu ilẹ mọlẹbi. Ninu ilana si ijẹ ninu ogun ti igba atijọ, wọn ka awọn obirin mọlẹbi kun apakan dukia fun eyi wọn jinna si ẹniti o ni ẹtọ rẹ labẹ ofin lati jogun gẹgẹbi ẹru. Nigbati o si jẹ pe ninu ofin Mose wọn gba pe awọn ọmọbirin ni ẹtọ si ogun nigbati ko ba si ọmọkunrin mọ, ṣugbọn wọn ko ka iyawo si ẹniti yio jogun koda ninu iru awọn aaye bayi"*[44] Kini idi ti wọn fi ri obirin mọlẹbi si apakan ohhun ini ẹbi? Rabbi Epstein ni idahun si eyi: *"Baba ni o niwọn ṣiwaju igbeyawo; ọkọ ni o si ni wọn lẹhin igbeyawo"*[45]

Wọn ko awọn ofin ogun ninu Bibeli jọ sinu **Numeri 27:1-11**. Wọn ko fun iyawo ni ipin kankan ninu dukia ọkọ rẹ, nigbati ohun (ọkọ) si jẹ akọkọ ninu awọn ẹniti o ni ẹtọ si ogun ninu dukia rẹ (iyawo), koda ṣiwaju awọn ọmọkunrin rẹ. Ọmọbirin le jẹ ogun nigbati ko ba si ọkunrin ti o lẹtọ si ogun. Iya ko ni ẹtọ kankan si ogun rara nigbati baba si ni ẹtọ si ogun. Nigbati awọn ọmọkunrin ba wa, awọn opo ati awọn ọmọbirin wa labẹ aanu awọn ọkunrin ajogun fun ipese. Nitori idi eyi ni awọn opo ati awọn ọmọbirin alailobi fi wa ninu awọn ẹniti wọn toṣi ju ni awujọ Juu.

Kristiẹniti ti wa lori ilana yi tipẹtipẹ. Ọkọọkan ninu ofin ile-isin ati ofin ara ilu ti agbaye Kristiẹni kọ fun awọn ọmọbirin nibi ipin dukia baba wọn pẹlu awọn arakunrin wọn. Ju bẹẹ lọ, gbogbo ẹtọ nini ipin ninu ogun ni wọn gba kuro lọwọ awọn iyawo. Awọn ofin aiṣedeede yi ṣi wa bẹẹ titi di ipari senturi ti o gbẹhin.[46]

Laarin awọn keferi Larubawa ki Islam to de, wọn fi awọn ẹtọ ogun rinlẹ fun awọn mọlẹbi ọkunrin nikan. Al-Qur'an pa gbogbo awọn aṣa aiṣedeede yi rẹ o si fun awọn obirin mọlẹbi ni awọn ipin ninu ogun:

*"Awọn ọkunrin ni ipin ninu ohun ti awọn odi ati ibatan (wọn) ba fi silẹ (ku), obirin na ni ipin ninu ohun ti awọn obi ati ibatan (wọn) ba fi silẹ (ku) ninu eyiti o kere tabi ọpọ rẹ, ipin ti a ti pinu rẹ ni"* **(Qur'an 4:7)**.

Awọn iya, iyawo, ọmbirin ati arabirin Musulumi ni wọn ti ni ẹtọ ninu ogun lati ọgọrun mẹtala ọdun ṣiwaju ki Europe to mọ wipe awọn ẹtọ yi ti ẹ nbẹ rara. Ipin ogun jẹ ọrọ ti o gbilẹ pẹlu awọn alaye ti o kun rẹrẹ **(Qur'an 4:7, 11, 12, 176)**. Ofin apapọ ni wipe ipin obirin jẹ idaji ipin ọkunrin ipin ọkunrin ayafi ni awọn aaye ti o jẹ wipe iya ma ngba ipin kanna ti baba ba gba. Ofin apapọ yi ti a bay a sọtọ lara awọn ofin miran ti o niṣe pẹlu awọn ọkunrin ati awọn obirin o le dabi wipe kosi deede. Lati wa gbọ agbọye ọgbọn ti o wa labẹ ofin yi, enia gbọdọ ni ni ero ohun ti o daju wipe awọn inawo ọranyan ti awọn ọkunrin ninu Islam pọju ti awọn obirin lọ ni jinajina (wo apa *"Awọn Ohun Ini Iyawo"*). Ọkọ gbọdọ fun iyawo aya rẹ ni ẹbun igbeyawo. Ẹbun yi yio di ohun ini rẹ nikan yio si wa bẹẹ titi koda ki o pada kọ ọ silẹ.

Kosi iyawo ni abẹ ọranyan kankan lati fun ọkọ rẹ ni eyikeyi ẹbun. Ju bẹẹ lọ, wọn paṣẹ fun ọkọ pẹlu wipe itọju iyawo ati awọn jẹ ojuṣe rẹ. Ni idakeji, wọn ko la a bọ iyawo lorun lati ran ọkọ rẹ lọwọ nipa eleyi. Ohun ini ati awọn dukia rẹ njẹ lilo ti ẹ nikan ayafi eyi ti o ba finufẹdọ yọọda fun ọkọ rẹ. Pẹlupẹlu, enia gbọdọ mọ wipe Islam ndaabo gidigidi bo igbesi aiye ẹbi. O ma ngba awọn ọdọ niyanju lati ṣe igbeyawo, o si nko irẹwẹsi itu yigi, kosi ka apọn kun iwa-ọrun. Nitorinaa, ni awujọ Islam tootọ, igbesi aiye ẹbi ni ilana, nigbati igbesi aiye apọn si jẹ iṣati. Eleyi ni wipe, ọpọlọpọ awọn obirin ati ọkunrin ti wọn ti to ṣe igbeyawo ni wọn ti ṣe igbeyawo ni awujọ Islam. Pẹlu tiitan imọlẹ si ododo yi, enia yio mọ wipe awọn ọkunrin Musulumi, ni apapọ, ni awọn ẹbiti inawo ti o tobi ju awọn obirin Musulumi lọ nibayi awọn ilana ogun wa lati gbe aiṣedeede yi kuro ki awujọ le la kuro ninu gbogbo awọn wahala ẹlẹya tabi ẹgbẹ. Lẹhin agbeyewo ranpẹ laarin awọn ẹtọ inawo ati awọn iwọ awọn obirin Musulumi, obirin Musulumi Biritipo kan wa pinu wipe ko ki nṣepe ẹsin Islam ṣe deede nikan pẹlu awọn obirin bi ki nṣepe o tun ni inu rere siwọn pẹlu.[47]

# APA 13 – IPO AWỌN OPO-BIRIN?

Nitori ohun ti o daju wipe Majẹmu Lailai ko mọ ẹtọ ogun fun wọn, awọn opo wa ninu awọn ẹniti wọn ṣe ipalara fun ju ninu awọn enia ti wọn jẹ Juu. Awọn ibatan ọkunrin ti wọn jogun gbogbo dukia ọkọ ti o ku ni wọn yio pese fun iyawo rẹ ninu dukia yi. Ṣugbọn, ko si ọna ti awọn opo le fi ni idaniloju pe ipese yi yio jẹ mimu ṣẹ, ti yio ma wa ṣẹmi labẹ aanu ẹlomiran. Nitori idi eyi, laarin awọn ẹgbẹ alaini ni awọn opo wa ni Israeli ni atijọ ti wọn si ka ijẹ opo si ami iyẹpẹrẹ ti o tobi **(Isaiah 54:4)**. Ṣugbọn ipo idamu ti awọn opo wa ninu aṣa atọwọdọwọ Bibeli pọju iyọ ọ kuro ninu awọn ti yio jogun dukia ọkọ rẹ lọ. Ni ibamu si **Gẹnẹsisi 38**, opo ti ko bimọ rara gbọdọ fẹ arakunrin ọkọ rẹ ni ọkọ, koda ki o (arakunrin ọkọ) ti gbeyawo tẹlẹ, ki o le jẹ wipe yio so eso fun arakunrin rẹ ti o ti ku, ki o le ni idaniloju bayi pe orukọ arakunrin ohun ko ni parun.

*"Judah si wi fun Onani pe, Wọle tọ aya arakunrin rẹ lọ, ki o ṣu u li opo, ki o si bimọ si ipo arakunrin rẹ"* **(Gẹnẹsisi 38:8)**.

Ki opo fi ọwọ si igbeyawo yi ko ki nṣe ohun ti wọn beere fun. Wọn ma nhuwa si opo gẹgẹbi apakan ninu ohun ini ọkọ rẹ ti o ku ti o jẹ pe olori iwulo rẹ ni ki o ni idaniloju wipe o ntele aṣẹ ọkọ rẹ. Wọn ṣi nlo ofin Bibeli yi ni Israeli titi di ode oni.[48] Wọn ma nṣu opo ti ko bimọ rara ni opo fun arakunrin ọkọ rẹ. Ti arakunrin ba ṣi kere lati gbe iyawo, o (opo) gbọdọ duro titi arakunrin yi yio fi dagba. Ṣugbọn ti arakunrin ọkọ ti o ku ba kọ lati gbe e (opo) ni iyawo, wọn yio tu silẹ lẹhinnaa yio ni ominira lati fẹ eyikeyi ọkunrin ti o ba wu. Ko ki nṣe ohun ti ko wọpọ ni Israeli wipe awọn arakunrin ọkọ wọn ma nba wọn ni orukọ jẹ lati gba anfani wọn.

Iru iṣesi bayi ni o lara awọn keferi Larubawa ki Islam to de. Wọn ka opo ku ipin kan ninu dukia ọkọ rẹ ti ẹniti o lẹtọ si ogun lọkunrin le jẹ mogun, bi tatẹhinwa, wọn ma nfi (opo) fun ẹniti o dagbaju lọkunrin ninu awọn ọmọ oku lati ọdọ miran. Al-Qur'an tako aṣa idojuti yi o si parẹ:

*"Ki ẹnyin ma si ṣe fẹ ẹniti awọn baba nyin ti fẹ ninu awọn obirin ayafi eyiti o ti ṣe sẹhin. Dajudaju o jẹ iwa ibajẹ ati ohun ikorira o si jẹ buburu"* **(Qur'an 4:22)**.

Wọn yẹpẹrẹ awọn opo ati awọn ilemoṣu ninu aṣa atọwọdọwọ Bibeli debi wipe olori alufaa ko gbọdọ gbe opo, ilemoṣu, tabi panṣaga obirin ni iyawo:

*"Wundia ni ki o fẹ li aya fun ara rẹ. Opo, tabi obirin ikọsilẹ, tabi ẹni-ibajẹ, tabi panṣaga, wọnyi ni on ko gbọdọ fẹ, bikoṣe wundia ni ki o fẹ li aya lati inu awọn enia rẹ, Bẹẹni ki o maṣe ba iru-ọmọ rẹ jẹ ninu awọn enia rẹ"* **(Lẹf. 21:13-15)**.

Ni Israeli loni, arọmọdọmọ idile Cohen (Olori alufaa awọn ọjọ Tempili) kan ko le fẹ obirin ikọsilẹ, opo, tabi panṣaga obirin.[49] Ninu ofin Juu, wọn ka obirin ti o jẹ opo fun igba mẹta ti awọn ọkọ mẹtẹẹta si ku iku adanida si 'apani' wọn si ṣe leewọ fun ki fẹ ọkọ miran.[50] Ni idakeji, Al-Qur'an ko mọ ẹnikẹni si ẹṣa tabi apani. Awọn opo ati awọn obirin ikọsilẹ ni anfani lati fẹ ẹnikẹni ti wọn bay an laayo.

Ko si alebu kankan ti o wa lara ikọsilẹ ipo opo ninu Al-Qur'an:

*"Nigbati ẹ ba kọ obirin silẹ ti wọn ba de opin igba wọn, yala ki ẹ mu wọn dani pẹlu daada tabi ki ẹ juwọn silẹ pẹlu daada. Ẹ ma mu wọn dani niti ipalara nitori ki ẹ le kọja ẹnu-aala. Ẹniti o ba ṣe bẹẹ dajudaju o ti bo ori ara rẹ si. Ẹ mu aaya Ọlọhun ni yẹyẹ"* **(Qur'an 2:231)**.

*"Ati awọn ti o ku ninu yin ti wọn si fi awọn iyawo silẹ, awọn obirin na ni lati kora ro fun oṣu mẹrin ati ọjọ mẹwa; lẹhinna nigbati nwọn ba de opin igba wọn ko si ẹṣẹ fun nyin nipa ohun ti wọn ba ṣe fun ara wọn ni ọna ẹtọ"* **(Qur'an 2:234)**.

*"Ati pe awọn ti o ba ku ninu nyin ti nwọn si fi awọn iyawo wọn silẹ, ki nwọn sọ asọtẹlẹ ti ipese fun awọn iyawo wọn titi di ọdun kan lai ko ni le wọn jade. Ṣugbọn ti wọn ba jade ko si ẹṣẹ fun nyin nipa ohun ti nwọn ba ṣe fun ara wọn ni ọna ẹtọ"* **(Qur'an 2:240)**.

# APA 14 – ILOBIRIN PUPỌ?

Ni bayi ẹ jẹ ki a bẹrẹ pẹlu ibeere pataki nipa ilobirin pupọ. Ilobirin jẹ iwa atijọ ti a ri ni ọpọlọpọ awọn awujọ enia. Bibeli ko da ikoyawojọ lẹbi. Ni ilodi si, Ni lẹmọlẹmọ ni Majẹmu Lailai ati awọn akọsilẹ awọn olukọni njẹri si wipe ilobirin pupọ ba ofin mu. Wọn ni ọba Solomon ni ọgọrun meje (ọọdẹgbẹrun) awọn iyawo ati awọn ọgọrun mẹta (ọọdunrun) awọn ale **(1 Awọn Ọba 11:3)**. Bakannaa, wọn ni ọba Dafidi ni ọpọlọpọ awọn iyawo ati awọn ale **(2 Samueli 5:13)**. Majẹmu Lailai ni awọn iyanju kan nipa bawo ni pinpin dukia ọkunrin kan laarin awọn ọmkunrin rẹ lati ara awọn iyawo ọtọọtọ **(Deut. 22:7)**. Aala kanṣo ti o wa lori ilobirin pupọ naa ni ifofin de igbe arabirin iyawo kan ni orogun si iyawo ẹni **(Lef. 18:18)**. Talmud ngbani nimọran iyawo mẹrin ni eyiti o o pọju lọ.[51] Awọn Juu ti Europe ṣi nni iyawo pupọ titi di senturi kẹrindilogun. Awọn Juu Ila-Oorun ma nni iyawo pupọ titi ti wọn fi padasi Israel ni ibi ti o ti jẹ ewọ labẹ ofin ilu. Ṣugbọn, ni abẹ ofin ẹsin eleyi ti o pa pa ofin agbelẹrọ ofin ilu rẹ ni iru awọn aaye bayi, o jẹ eyiti wọn yọnda rẹ.[52]

Bawo ni nipa Majẹmu Titun? Ni ibamu si Father Eugene Hillman ninu iwe awotunwo rẹ, Polygamy reconsidered, *"Kosi ibi kankan ninu Majẹmu Titun ti ofin ti o fojuhan kan wa eleyi ti o ni igbeyawo gbọdọ jẹ ẹyọkan tabi ti ofin gbogi kan ti nṣe igbeyawo pupọ ni ewọ"*.[53] Jubẹlọ, Jesu ko sọ ohun ti o tako ilobirin pupọ biotilẹjẹpe awọn Juu ti o wa ni awujọ rẹ nṣe e. Father Hillman nsọ ohun ti o daju wipe Ile-Ijọsin ni Rome fofin de ilobirin pupọ ki wọn le ba tele aṣa Greco-Roman (eleyi ti o paṣe iyawo kan ni eyiti o ba ofin mu nigbati o si fi aaye gba iyan ale ati ifi agbere ati panṣaga ṣe owo.) O fi ọrọ St. Augustine ṣẹri: *"Nibayi nitootọ ni asiko tiwa, ni ikẹgbẹ pẹlu aṣa Rome, a ko fi aye gba a mọ ki ẹnikẹni fẹ iyawo keji"*.[54]

Awọn Ile-Ijọsin ti African (ilẹ Alawọ dudu) ati awọn Kristiẹni Iran Alawọ dudu nran awọn ọmọ iya wọn ni Europe leti wipe ifofin de ilobirin pupọ ti Ile Ijọsin jẹ aṣa atọwọdọwọ atipe ko ki nṣe ojulowo aṣẹ Kristiẹni.

Bakannaa, Al-Qur'an yọọda ikobirin jọ, ṣugbọn ko ki nṣe laipa aala si:

*"Bi ẹnyin ba nbẹru pe ẹ ki yio le ṣe dede npa ọmọ-orukan, njẹ ẹ fẹ eyiti o ba dara niti nyin ninu awọn obirin, meji tabi mẹta tabi mẹrin, ṣugbọn bi ẹnyin ba nbẹru pe ẹ ki yio ṣe dede (larin wọn) njẹ (ẹ fẹ) ọkanṣoṣo"* **(Qur'an 4:3)**.

Al-Qur'an, ni idakeji Bibeli, fi odiwọn si eyitopọju niye awọn iyawo si mẹrin labẹ majẹmu ti o muna ti iṣetoju awọn iyawo yi pẹlu dọgbadọgba ati dede. A ko gbọdọ gbọye wipe Al-Qur'an nṣe awọn onigbagbọ ni ojukokoro lọsi ibi ikoyawo pupọ jọ, tabi wipe o ri ilobirin pupọ si apẹrẹ ti ko lẹgbẹ. Ni gbolohun miran, Al-Qur'an ṣe *"igbalaaye"* tabi *"yọọda"* ilobirn pupọ, ko si ju bẹẹ lọ, ṣugbọn nitori kini? Kini idi iyọọda ilobirin pupọ? Idahun rẹ jẹ eyiti o rọrun: awọn aaye ati awọn akoko kan wa ni eyiti awọn idi awujọ ati iṣe nsọ ilobirin pupọ di ọranyan. Gẹgẹbi ẹsẹ Al-Qur'an ti o wa loke ti nṣe afihan rẹ, aworan ilobirin pupọ ninu Islam ko le jẹ eyiti a o gbọye ni yiya sọtọ kuro ninu igbesẹ awọn ara ilu sọdọ awọn ọmọ orukan ati awọn opo-birin. Islam gẹgẹbi ẹsin gbogbo aiye ti o si ba gbogbo aaye ati asiko mu kole foju rena awọn igbese ti nṣe ọranyan wọnyi.

Ni ọpọlọpọ awọn awujọ enia, onka awọn obirin ju onka awọn ọkunrin lọ. Ni U.S. nkan bi ẹgbẹrun lọna ẹgbẹrun mẹjọ (eight million) ni obirin fi pọ ju awọn ọkunrin lọ. Ni orilede bi Guinea ọgọrun ati mejilelogun (122) awọn obirin ni o wa fun gbogbo ọgọrun (100) kọọkan awọn ọkunrin. Ni Tanzania, 95.1 awọn ọkunrin ni o wa fun ọgọrun kan awọn obirin.[55] Kini awujọ kan le ṣe nipa aiṣe dọgbadọgba iwọn akọ ati abo bayi? Oniranran awọn ọna abayọ ni o wa, awọn kan le damọran ima wa ni apọn, awọn miran si le yan pipa ọmọbirin laayo (eleyi ti o nṣẹlẹ ni awọn awujọ kan ni agbaiye loni !). Awọn miran si le ro wipe ọna abayọ kanṣoṣo ti o wa naa ni wipe ki wọn fi aaye gba gbogbo ọna ibalopọ laarin ọkunrin ati obirin ni awujọ: iṣẹ agbere, ilopọ ọkunrin pẹlu obirin laisi asopọ mimọ laarin wọn, ibalo ọkunrin sọkunrin ati ibalo obirin sobirin, etc. Fun awọn awujọ miran, bi ọpọlọpọ awọn awujọ Afrcan (Iran Alawọ dudu) loni, ọna abayọ ti o niyin ju lọdọ wọn ifi aaye gba ilobirin pupọ ni eyiti o ba aṣa ati iṣe awujọ mu. Ohun ti awọn ara iwọ-oorun ko gbọye ni wipe awọn obirin ninu awọn aṣa miran ko ri ikobirin jọ gẹgẹbi apẹẹrẹ abuku fun awọn obirin. Ni apejuwe, ọpọlọpọ awọn ọmọge iyawo Alawọ dudu, boya Kristiẹni ni abi Musulumi tabi bibẹẹkọ, ni o yan lati fẹ

ọkunrin ti o ti gbeyawo sile tẹlẹ ẹniti o ti ṣe afihan ara rẹ ni ọkọ ti o ṣe gbara le.

Ọgọọrọ awọn iyawo Alawọ dudu ni wọn ma nbẹ awọn ọkọ wọn lati ni iyawo keji ki wọn ma ba ifuramọ idawa.[56] Iwadi kaakiri lọdọ awọn obirin ti wọn ju ẹgbẹrun mẹfa lọ (six thousand), ti ọjọ ori wọn wa lati mẹẹdogun si mọkandilaadọta (15 to 59), ti o waiye ni ilu ẹlẹẹkeji ti o tobi ju ni Nigeria fihan pe ọgọta ninu ọgọrun (60%) ninu awọn obirin wọnyi ni yio jẹ itẹlọrun fun ti awọn ọkọ wọn ba fẹ iyawo miran. Awọn mẹtalelogun (23%) pere ni wọn fi ẹhonu han lori iro ipin ọkọ wọn pẹlu iyawo miran. Aadọrin ninu ọgọrun (70%) awọn obirin ni wọn ri aṣa ikobirin jọ ni ohun ti o dara ninu iwadi kaakiri ti o waiye ni Kenya.

Ninu iwadi kaakiri kan ti wọn gbidanwo rẹ ni oko Kenya, mẹẹdọgbọn ninu mẹtadilọgbọn (25 out 27) awọn obirin ni wọn ri wipe ilobirin pupọ dara ju ilobirin kan lọ. Awọn obirin yi ri wipe ilobirin pupọ le jẹ iriri ayọ ati anfani ti awọn ti awọn iyawo yi ba ni ifọwọsowọpọ pẹlu ara wọn.[57] Ilobirin pupọ ni ọpọlọpọ awọn awujọ Iran Alawọ dudu (African) jẹ agbekalẹ kan ti o niyin debi wipe awọn ile ijọsin Alatẹnumọ kan fi nṣe amojukuro rẹ. Bishop kan ti ile ijosin Anglican ni Kenya ṣekede wipe: *"Biotilẹjẹpe ilobirin kan le jẹ apẹrẹ fun iṣe afihan ifẹ laarin ọkọ ati aya, ile ijọsin (church) gbọmọ mọ wipe ninu awọn aṣa kan ilobirin pupọ jẹ itẹwọgba lawujọ ati wipe igbagbọ wipe ilobirin pupọ nlodi si ẹsin Kristiẹniti ko ki nṣe ohun ti a le gba mọ".*[58]

Lehin iṣe ayẹwo kikun nipa ilobirin pupọ ni ilẹ Alawọ dudu, Ẹniọwọ (Reverend) David Gitari ti ile ijọsin Anglican ti pinu wipe ilobinrin pupọ, ni biwọn ti nṣe, o jẹ eyi ti o ba ẹsin Kristiẹni mu ju ikọ obirin silẹ pẹlu itun igbeyawo ṣe lọ ni odiwọn igba ti o ba jẹ pe o niṣe pẹlu awọn iyawo ati awọn ọmọ ti a kọ silẹ.[59] Emi nitemi mọ awọn iyawo Iran Alawọ dudu kan ti wọn si jẹ ẹlẹkọ gidi, pẹlu wipe wọn gbe ni Iwọ-Oorun fun ọpọlọpọ ọdun wọn ko ni eyikeyi atako kankan si ilobirin pupọ. Ọkan ninu wọn ti o ngbe ni U.S., fi tinutinu rọ ọkọ rẹ lati fẹ iyawo keji lati le kun u lọwọ nibi iṣetọju awọn ọmọ.

Iṣoro aidọgba ẹya akọ ati abo ma njẹ idamu gidi ni awọn asiko ogun. Awọn ẹya America India ni ibi ma njiya aidọgba ẹya leyi ti o ga ju lẹhin awọn adanu ni asiko ogun. Awọn obirin ninu awọn ẹya wọnyi, awọn ti o jẹ wipe ni

otitọ wọn nje igbadun ipo giga, tẹwọgba aṣa ikobirin jọ gẹgẹbi aabo ti o dara julọ kuro nibi ikẹ awọn igbesẹ aitọ. Awọn atipo Europe, laimu ọna abayọ miran wa,bu ẹnu atẹ lu aṣa ilobirin pupọ awọn India yi wọn si ka kun *"ailaju"*.[60] Lẹhin ogun agbaye ẹlẹẹkeji,7,300,000 ni awọn obirin fi pọju awọn ọkunrin lọ ni Germany (awọn 3.3 million ninu wọn ni wọn jẹ opo).

Ọgọrun (100) ọkunrin ti ọjọ ori wọn jẹ 20 si 30 ni wọn wa fun 167 awọn obirin ni iru ọjọ ori yi.[61] Ọgọọrọ awọn obirin yi ni wọn ni bukata si ọkunrin kan kosi ki nṣe gẹgẹbi ẹnikeji nikan bi ki nṣe gẹgẹbi olupese fun idile ni asiko oṣi airotẹlẹ ati ipọnju. Awọn ọmọ-ogun Allied Armies ti o bori ninu ogun lo ipalara awọn obirin wọnyi. Ọpọlọpọ awọn obirin ewe ati awọn opo ni wọn ni ibalopọ pẹlu awọn ologun ti wọn wa lori ilẹ wọn. Ọpọlọpọ awọn jagunjagun ti America ati Britipo ni wọn fi taba (cigcrettes), koko lilọ (chocolate), ati akara oyinbo (bread) sanwo faaji ti wọn ni pẹlu wọn. Awọn ọmọde dunu kọja ala si awọn ẹbun ti awọn alejo yi kowa.

Ọmọ ọdun mẹwa ọmọdekunrin kan nigbati ọ gbọ nipa iru ẹbun bayi lati ọdọ awọn ọmọde miran ohun naa wa fẹ lati inu ẹmi rẹ "Oyinbokunrin" kan fun iya rẹ tie bi ko fi ni pa a mọ.[62]

Ani lati beere ninu ara wa ni aaye yi: Ewo ni o jẹ apọnle fun obirin ju? Itẹwọgba ati ibuyin fun iyawo keji gẹgẹbi o ti wa lọdọ awọn India, tabi aṣẹ agbere bi o ti wa ninu "ọlaju" Allies Armies? Ni gbolohun miran, ewo ni o koyi ba obirin julọ, ṣe ilana Al-Qur'an ni tabi imọ ti o dalori aṣa Ijọba alagbara Rome?

O pọn dandan lati ṣe akiyesi wipe ninu apero ọdọ agbaye kan ti o waye ni Munich ni 1948 iṣoro aidọgba ẹya akọ ati abo ti o gaju ni Germany ni wọn sọrọ le lori. Nigbati o fi ojuhan wipe kosi ọna abayọ kan ti wọn fẹnuko le lori, awọn akopa kan da aba ilobirin pupọ. Akọkọ esi ikojọpọ yi jẹ adalu idugbolu ati ikorira. Ṣugbọn, lẹhin akiyesi finifini si imọran yi, awọn akopa fẹnuko wipe ohun nikan ni ọna abayọ ti o ṣiṣẹ. Tobaribẹ, wọn fi ilobirin pupọ sinu awọn ohun ti wọn sọ si rere.[63]

Agbaiye loni ni wọn ni ohun ija apaiyerun ni ikawọ ju ti tẹlẹ lọ atipe awọn ile ijọsin ti Europe ṣile, pẹ tabi ya, rọ lati gba ilobirin pupọ gẹgẹbi ọna abayọ

kanṣoṣo. Father Hillman ti lero imọ ohun ti o daju yi, *"O jẹ ohun ti o ba laka wipe awọn ọna genocidal (ẹrọ iparun, ẹkọ nipa ẹda, elo ipilẹ ti a fi nmu ohun miran jade..) le mu aiṣe dọgbadọgba rara jada laarin awọn ẹya akọ ati abo eleyi ti yio wa pada sọ ikobirinjọ di ọna abayọ kanṣoṣo... Nigbanaa yio jẹ idakeji si aṣa ati ofin ti o ṣaju, ifa ọkansi adamọ ati iṣe ti wọn ti tẹri le wa dide ni ikin ilobirin pupọ lẹhin. Ni iru aaye bayi, awọn ọlọgbọn ninu kika ọrọ Ọlọhun ati awọn aṣaaju ile ijọsin yio sare wa awọn idi ti o rinlẹ ati awọn ọrọ inu Bibeli lati gbe iro igbeyawo titun yẹwo".*[64]

Titi di akoko yi, ilobirin pupọ ntẹsiwaju ni ijẹ ọna abayọ kanṣoṣo si awọn aisan ibakẹgbẹ ti awujọ ode oni. Awọn ọranyan gbogboogbo ti Al-Qur'an mu ẹnu ba ni ibamu pẹlu iyọọda ilobirin pupọ jẹ eyiti aaye rẹ yọ silẹ ni asiko yi ni awọn awujọ Iw-Oorun kan ju ni Ilẹ Alawọ dudu lọ. Fun apejuwe, ni United State loni, aawọ ti o muna wa nipa ẹya akọ ati abo ni awujọ awọn ẹya dudu. Ikan ninu gbogbo ogun (every twenty) awọn ọkunrin dudu ti wọn jẹ ọdọ ni wọn le ku ki wọn to di ọmọ ọdun mọkanlelogun. Fun awọn ti wọn wa laarin ogun ọdun ati ọdun marundilogun, ipania ni o ngbawaju nibi iṣe okunfa iku wọn.[65]

Lẹhinna, ọgọọrọ awọn ọkunrin ọdọ ninu awọn dudu ni wọn koni iṣẹ lọwọ, ni wọn wa ni ẹwun, tabi ni wọn nmu awọn nkan oloro.[66] Ni abajade eyi, ikan ninu mẹrin awọn obirin dudu, ti wọn jẹ ogoji ọdun , ni wọn ko ti ni ọkọ, ni ifiwe ikan ninu mẹwa awọn obirin funfun.[67]

Jubẹlọ, ọpọlọpọ awọn obirin dudu ti won jẹ ọdọ ni wọn ndi ilemoṣu ṣiwaju ki wọn to di ọmọ ogun ọdun ti wọn si nba ara wọn ni ẹniti o ni bukata si awọn olupese. Abajade awọn iṣẹlẹ oloro yi ni wipe onka ti o pọ ninu obirin dudu ni wọn nṣe ohun ti wọn npe ni 'ajọpin ọkunrin'[68]

Eleyi nipe, ọpọ ninu awọn apọn obirin dudu ti ko ni ori ọkọ yi ni wọn nni ibalopọ pẹlu awọn ọkunrin ti wọn ti iyawo. Awọn iyawo paapa ko nimọ wipe awọn obirin miran 'npin' awọn ọkọ wọn pẹlu wọn. Awọn olukiyesi aawọ ipin ọkunrin ni awujọ awọn Alawọ dudu America fọwọsi ikobirinjọ gẹgẹbi iwayanju si fun igba diẹ si ẹdin awọn ọkunrin dudu titi ti awọn atunṣe yio fi waiye awujọ America ni apapọ.[69]

Ero wọn pẹlu ilobirin pupọ ti wọn fọwọsi ni wipe ilobirin pupọ eleyi ti ara ilu yọọda ati eleyi ti gbogbo awọn ti o ba kan fi ẹnu ko le lori, bi o ti jẹ pe o doju ija kọ iṣe-ipin ọkunrin ni bonkẹlẹ eleyi ti o nko ipalara ba iyawo ati ara ilu ni apapọ. Iṣoro ipin ọkunrin ni laarin Iran Alawọ dudu America ni akọle ajọ ijiroro ti o waiye ni Temple University ni Philadelphia ni January 27, 1993.[70] Awọn kan ninu awọn ti wọn sọrọ royin ilobirin pupọ gẹgẹbi atunṣe tolagbara kanṣo ti o wa fun aawọ yi. Wọn tun daba wipe wọn ko gbọdọ fi ofin de ikobirinjọ, patakijulọ awujọ ti o fi aaye gba panṣaga ati ale. Afikun obirin kan lati inu oluworan ni wipe awọn Iran Alawọ dudu America ni lati kọ lọdọ Africa nibi ti wọn ti nlo aṣa ilobirin pupa bi o titọ ati bi o ti yẹ mu pipa atẹwọ jade lati ọdọ awọn ti ọrọ naa wọ lara.

Philip Kilbride, ọmọ America onimọ nipa enia ati abara ti Roman Catholic Heritage, ninu iwe fọrifọri rẹ, Ilobirin pupọ fun akoko, o ndamọran ikobirinjọ gẹgẹbi ọna-abayọ si awọnkan ninu awọn aisan awujọ America lapapọ. O njiyan wipe igbeyawo pupọ le duro gẹgẹbi ọna gidi miran dipo ikọ obirin silẹ ni ọpọlọpọ igba lati gbagbe oripa adanu ikọ obirin silẹ lara ọpọlọpọ awọn ọmọ. O ntẹnumọ wipe ọpọlọpọ awọn ikọ obirin silẹ ni o waiye lati ara idagbasoke iyan ale ni awujọ America. Ni ibamu si Kilbride, ifopin si iyan ale ninu aṣa ikobirin jọ, sanju ikọ iyawo silẹ lọ, ni o si dara ju fun awọn ọmọ, *"Awọn ọmọ yio ri itọju daada gba ti wọn bay an idagbasoke ẹbi laayo ju ipinya ati ituka nikan ti wọn ri gẹgẹbi bi ifẹ"*. Jubẹlọ, o gba ni imọran wipe awọn ijọ miran yio tun ri anfani lati ara ilobirin pupọ, awọn bi: awọn obirin agbalagba ti wọn nkoju iṣoro aito awọn ọkunrin ati awọn Ẹya Alawọ dudu America ti wọn nṣe ipin ọkunrin.[71]

Ni 1987, ikọ idibo kan waiye ti iwe irohin ọmọ-akẹkọ (student newspaper) ni University of Califonia ni Berkeley ṣe agbatẹru rẹ beere lọwọ awọn ọmọ-akẹkọ wipe boya wọn fi ọwọ si wipe gbọdọ fi aaye gba awọn ọkunrin lati ni ju iyawo kan lọ ni idahun si iwoye ẹdin awọn ọkunrin akopa ninu igbeyawo ni Califonia. O fẹ jẹ gbogbo awọn ọmọ-akẹkọ ti wọn kopa ni wọn fi ọwọ si iro yi. Koda ọmọ-akẹkọbirin kan sọ lẹsẹsẹ wipe ilobirin pupọ yio jẹ irẹlẹkun ẹdun ọkan awọn ohun ti o nfẹ nigbati yio fun ni ominira ti o tobi ju idapọ oniyawokan lọ.[72] Ni ohun todaju, iṣaroye yi kannaa ni awọn fundamentalist Mormon women ti wọn ṣi nlo aṣa iyawo pupọ ni U.S. lo. Wọn ni igbagbọ wipe ilobirin pupọ jẹ ọna ti o dara ju fun obirin lati ni mejeeji ninu ilọsiwaju

ati awọn ọmọ nigbati o jẹ wipe awọn iyawo ti wọn nran ara wọn lọwọ nṣe akakun itọju awọn ọmọ.[73]

A gbọdọ fikun wipe ilobirin pupọ ninu Islam jẹ ohun ti tọtun tosi gbọdọ yọnu si. Ko si ẹniti o le jẹ obirin kan nipa lati fẹ ọkunrin ti o ti iyawo nile. Bakannaa, iyawo ni ẹtọ lati ṣe ipinnu wipe ọkọ ohun ko gbọdọ fẹ obirin miran ni iyawo ẹlẹẹkeji.[74] Ni ẹgbẹ keji, Bibeli ma njẹ ilobirin pupọ nipa. Opo-birin ti ko bimọ gbọdọ fẹ arakunrin ọkọ rẹ ti o ku, koda ki o ti gbeyawo tẹlẹ (wo apa: *Ipo awọn Opo-birin*), laini ifohunsi rẹ. **(Gẹnẹsisi 38:8-10)**.

Agbọdọ ṣe akiyesi wipe ni ọpọlọpọ awọn awujọ Musulumi loni ilobirin pupọ ṣọwọn nigbati aafo ti o wa laarin onka awọn ẹya mejeeji ko tobi ju. Ẹnikan le sọ wipe, iye igbeyawo olobirin pupọ ti o wa ni agbaiye Musulumi o kere pupọ niye si ifẹ bokẹlẹ ti o wa ni Iha Iwọ-Oorun (West). Ni gbolohun miran, awọn ọkunrin ni agbaiye Musulumi loni nṣe igbeyawo olobirinkan ju awọn ọkunrin ti agbaiye Iha Iwọ-Oorun lọ.

Billy Graham, Kristiẹni ẹniọwọ mọ ohun ti o daju yi: *"Kristiẹniti ko le fi ẹnuko nipa iyemeji ikobirinjọ. Ti Kristiẹniti ode oni ko ba le ṣe bẹ ẹ, ohun ni o da ni wahala rẹ. Islam ti yọọda ilobirin pupọ ni ijẹ ọna-abayọ si awọn aisan awujọ, o si ti ṣe amojukuro odiwọn ibu kan pato fun adamọ enia ṣugbọn laarin ilana ofin ti a mọ eleyi ti o muna. Awọn orileede Kristiẹni nṣe afihan ilobirin lọna tọpọ, ṣugbọn nitootọ iwa ilobirin pupọ ni wọn nhu. Kosi ẹniti ko mọ nipa ale yiyan ti wọn nṣe ni awujọ Iwọ-Oorun. Nibiyi Islam ni ẹsin ipinlẹṣẹ ti ko ni eru ninu, o si nyọọda fun Musulumi lati fẹ iyawo ẹlẹẹkeji ti o ba jẹ dandan fun, ṣugbọn o kọ gbogbo awọn ọya ajọṣepọ bokẹlẹ lati le dabo bo iwa rere inukan ara ilu kuro ninu ewu"*[75]

O ṣe pataki lati ṣe akiyesi wipe ọpọlọpọ -ẹniti ki nṣe Musulumi bakannaa Musulumi- awọn orilede ni agbaiye loni ni wọn ti fofin de ilobirin pupọ. Igbe iyawo keji, koda ki o jẹ pẹlu ifohunsi akọkọ, jẹ eyiti o ṣẹ si ofin. Ni idakeji, iyan iyawo jẹ, laisi imọsi tabi ifohunsi rẹ, jẹ eyiti wọn ṣe ni ẹtọ ni ibamu si ofin! Kini oye ofin ti o wa ni abẹ iru ita ododo bayi? Njẹ wọn gbe ofin kalẹ lati ta abosi lọrẹ ni pẹlu ifiya jẹ otitọ? O jẹ ọkan ninu ọrọ meji ti o ṣe biẹnipe nwọn yatọ si ara wọn ti a ko si le ri idi rẹ ti aiye 'ọlaju' wa ti ode oni.

# APA 15 – IBORI?

Lakotan, ẹ jẹ ki a tan awọn imọlẹ diẹ si ohun ti wọn ni Iwọ-Oorun wipe o jẹ ami titobi julọ fun inilara ati imu awọn obirin sin lẹru, ibori tabi ideri. Njẹ otitọ ni wipe kosi iru ikan bayi bi ibori ninu aṣa atọwọdọwọ Juu-Kristiẹni? Jẹ ki a fi ijẹri lela tara. Ni ibamu si Olukọni (Rabbi) Dr. Menachem M. Brayer (Professor of Biblical Literature, ni Yeshiva University) ninu iwe rẹ, The Jewish woman in Rabbinic Literature, aṣa awọn obirin Juu ni lati si ita gbangba pẹlu bibo ori, eleyi ti, nigbamiran, koda wọn ma nbo gbogbo oju ti wọn yio si yọ ẹyin iju kan silẹ.[76] O si ntun ọrọ awọn gbajumọ Olukọni atijọ muwa, *"Ko ki nṣe bi awọn ọmọbirin Israeli ni yio ma rin nigboro lai bo awọn ori wọn"* ati *"Egbe fun ọkunrin ti o jẹ ki wọn ma ri irun iyawo rẹ... obirin ti o ṣi irun rẹ si gbangba niti faari ma nfa oṣi"*. Ofin Rabbinic nda nṣe leewọ iṣe afọmọ tabi adua nibi ti iyawo-ile ti o ṣi ori silẹwa nigbati o jẹ wipe wọn ka ṣiṣi ori silẹ obirin si *"ihoho ara"*.[77]

Dr. Brayer tun nmẹnuba bakannaa wipe *"Ni akoko Tannaitic wọn ka ikuna obirin Juu lati bo ori rẹ si kun iko iyẹpẹrẹ ba ọmọluwabi rẹ. Nigbati ori rẹ ba wa ni ṣiṣi silẹ wọn le ni ki o san ọgọrun mẹrin (400) zuzim fun itanran ẹṣẹ yi"*. Dr. Brayer tun nṣe alaye wipe iboju awọn obirin Juu ni gbogbo igba kọ ni o jẹ ami ijẹ ẹni mimọ. Nigbamiran, ibori ma njẹ apẹrẹ ipo ati igbadun bokanran ijẹ ẹni rere. O si tun ma nduro fun obirin ti ko le sunmọ gẹgẹbi ipo mimọ ti ọkọ rẹ.[78]

Ibori nfi ijẹ ẹni-apọnle ati ipo obirin lawujọ han. Awọn obirin ti wọn rẹlẹ ni awujọ naa ma nlo ibori nigba pupọ lati fi sami pe ẹni giga ni awọn naa lawujọ. Ohun ti o daju gan ni wipe iboju jẹ ami ipo ọla ni idi ti wọn ko fi gba awọn oni panṣaga laaye lati bo irun wọn ni awujọ Juu latijọ. Sibẹsibẹ, ni igba kugba awọn aṣewo naa ma nfi aṣọ penpe kan bo ori wọn ki awọn naa le jọ enia lawujọ.[79] Awọn obirin Juu ti wọn wa ni Europe ṣi nlo awọn ibori wọn titi ti o fi di ọgọrun ọdun mọkandilogun nigbati iṣe wọn dapọ pẹlu aṣa awọn ti o yiwọn po. Awọn ifunlẹ mọni ti o han ti igbesi aiye Europe ni ọgọrun ọdun mọkandilogun yi jẹ ọpọlọpọ wọn nipa lati ma jade si igboro ni ṣiṣi ori silẹ. Awọn obirin Juu kan ri pe mima fi irun ti wọn ṣe fun awọn apari bori rọrun daada lati fi rọpo aṣa ibori wọn. Loni, ọpọ ninu awọn obirin Juu ẹlẹsin

ni wọn ki nbori wọn ayafi ni synagogue.[80] Apakan ninu wọn, awọn bi ẹgbẹ Hasidic, ṣi nlo irun ti wọn ṣe fun awọn apari.[81]

Bawo wani nipa aṣa Kristiẹni? Ohun gbogbo enia mọ ni wipe awọn Obirin Alufaa ninu ijọ Aguda (Catholic) ti nbo awọn ori wọn fun ọgọọgọrun awọn ọdun seyin, amọṣa eyi ko tan sibẹ, St. Paul sọ awọn ọrọ toladun kan nipa ibori ninu Majẹmu Titun:

*"Ṣugbọn mo fẹ ki ẹnyin ki o mọ pe, Kristi li ori olukuluku ọkunrin; ori obirin si li ọkọ rẹ; ati ori Kristi si li Ọlọrun. Olukuluku ọkunrin ti ngbadura tabi ti nsọtẹlẹ ti o bo ori rẹ, o ṣe alaibọwọ fun ori rẹ. Ṣugbọn olukuluku obirin ti ngbadura tabi ti nsọtẹlẹ li aibo ori rẹ, nitori ọkanna ni pẹlu ẹniti o fari. Nitori bi obirin ko ba bo ori rẹ, ẹ jẹ ki o rẹ irun rẹ pẹlu, ṣugbọn bi o ba ṣepe ohun itiju ni fun obirin lati rẹ irun tabi lati fari rẹ, jẹ ki o bo ori. Nitori nitootọ koyẹ ki ọkunrin ki o bo ori rẹ, niwọnbi o ti jẹ aworan ati ogo Ọlọrun, ṣugbọn obirin ni iṣe ogo ọkunrin. Nitori ọkunrin ko ti ara obirin wa, ṣugbọn obirin ni o ti ara ọkunrin wa. Bẹẹni a ko da ọkunrin nitori obirin; ṣugbọn a da obirin nitori ọkunrin. Nitori eyi li o fi yẹ fun obirin lati ni ami aṣẹ li ori rẹ, nitori awọn angẹli"* **(1 Awọn Ara Korinti 11:3-10)**.

Oye St. Paul nipa bibo obirin lori ni wipe ibori nduro fun ami ipo ọkunrin, ti o jẹ aworan ati ogo Ọlohun, lori obirin eyiti wọn da lati ara ati fun ọkunrin pẹlu. St. Tertullian ninu ihin rẹ olokiki 'On The Veiling Of Virgins' o kọ sibẹ, *"Obirin ọdọ, ẹ lo awọn ibori yin jade ni opopo, bẹẹni ẹ gbọdọ wọ wọn ninu ile ijọsin, ki ẹ wọ wọn nigbati ẹ ba wa laarin awọn alejo, ki ẹ si tun wọ wọn nigbati ẹ ba wa laarin awọn arakunrin yin…"* Ninu awọn ofin Canon ti ile ijọsin Aguda (Catholic) loni, ofin kan wa ti o nbere fun ki awọn obirin bo ori wọn ninu ijọ.[82] Awọn ijọ Kristiẹni kan, awọn bi Amish ati Mennonites fun apẹrẹ, njẹ ki awọn obirin wọn ma bori titi di ọjọ oni. Ero ti o wa nidi ibori, bi awọn olori ile ijọsin wọn ti sọ, ni wipe *"Mima bori jẹ ami itẹriba obirin fun ọkunrin ati Ọlọhun"*, eleyi ti o jẹ ọgbọn kannaa ti St. Paul muwa ninu Majẹmu Titun.[83]

Lati inu gbogbo ẹri ti o wa loke yi, o jẹ ohun ti o farahan wipe Islam kọ ni o pilẹ ibori. Ṣugbọn Islam fi ọwọ si. Al-Qur'an nrọ awọn onigbagbọ lọkunrin

ati lobirin lati rẹ oju wọn nilẹ ki wọn si ṣọ ọmọluwabi wọn o si tun nrọ awọn onigbagbọ lobin lati jẹ ki ibori wọn bo ọrun ati igbaya:

*"Sọ fun awọn olugbagbọ ododo lọkunrin pe ki nwọn maa rẹ oju wọn silẹ ati ki nwọn ṣọ abẹ wọn… Ati ki o sọ fun awọn olugbagbọ ododo lobirin pe ki awọn naa maa rẹ oju wọn silẹ ati ki wọn si ṣọ abẹ wọn ati ki nwọn ma si ṣe afihan ọṣọ wọn ayafi eyiti ko le ṣai han ninu rẹ. Ati ki nwọn ma fi ibori wọn le ori ẹwu wọn…"* **(Qur'an 24:30, 31)**.

Al-Qur'an fihan yekeyeke wipe ibori jẹ ohun koṣemani fun iṣọ ọmọluwabi, ṣugbọn kini idi ti iṣọ ọmọluwabi fi ṣe pataki? Al-Qur'an ṣi nṣe alaye:

*"Irẹ Anabi, sọ fun awọn iyawo rẹ ati awọn ọmọbirin rẹ ati awọn obirin awọn olugbagbọ ododo pe ki nwọn jẹ ki awọn aṣọ jalabu wọn ma balẹ. Eyi ni o dara lati le fi mọ wọn yatọ, ki wọn ma ba ma yọ wọn lẹnu"* **(Qur'an 33:59)**.

Eleyi ni gbogbo ohun ti a nsọrọ nipa rẹ, wọn gbe ilana imura daada kalẹ lati le da aado bo awọn obirin kuro nibi iyọlẹnu tabi kiki, imura daada jẹ aabo. Bayi, idi pataki kanṣo fun ibori ninu Islam ni aabo. Ibori ninu Islam, ko ki nṣe bi ibori ti aṣa Kristiẹni, ko ki nṣe ami ipo/agbara ọkunrin lori obirin tabi ami itẹriba obirin fun ọkunrin. Ibori ninu Islam, ko ki nṣe bi ibori ti aṣa Juu, ko ki nṣe ami igbadun ati iṣeyatọ awọn obirin iyawo ọlọla. Ibori ti Islam jẹ ami iṣọ ọmọluwabi ẹni ni ero ida aabo bo awọn obirin, gbogbo obirin. Ọgbọn Islam ni wipe wiwa ni alaafia san ju ikaanu lọ. Ni ikan ti o daju, Al-Qur'an ka idaado bo ara awọn obirin ati orukọ rere awọn obirin kun gan, nitorinaa eyikeyi ọkunrin ti o ba le lo ẹtan ifi ẹsun aimọ kan obirin, wọn yio jẹ niya ti o lapẹẹrẹ:

*"Awọn ti nwọn pe (panṣanga) mọ awọn obirin ti wọn ki i ṣe oni panṣaga, lẹhinna ti nwọn ko ri ẹlẹri mẹrin mu wa, ẹ na wọn ni ọgọrun ẹgba ẹ ko si gbọdọ gba ẹri wọn lailai, awọn eleyi ni poki"* **(Qur'an 24:4)**.

Ni fifi iwa ti o lagbara ti Al-Qur'an yi we ijẹniya ti o dẹra patapata ti o wa fun ẹsun ifipa banilo ti inu Bibeli: *"Bi ọkunrin kan ba si ri ọmọbirin kan ti iṣe wundia, ti a ko si fẹsọna fun ọkọ, ti o si mu u, ti o si ba a dapọ, ti a si mu*

*wọn. Njẹ ki ọkunrin na ti o ba a dapọ ki o fi aadọta sekeli fun baba ọmọbirin na, ki on ki o si maa ṣe aya rẹ, nitoriti o ti tẹẹ logo, ki on ki o maṣe kọ ọ silẹ li ọjọ aiye rẹ gbogbo"* **(Deut. 22:28-30)**.

Ẹnikan gbọdọ beere ibeere ranpẹ kan ni ahin, tani ẹniti wọn jẹniya gangan? Ṣe ọkunrin ti o kan sanwoya pere lori ẹsun ifipa banilo ni, tabi ọmọbirin ti wọn jẹ nipa lati fẹ ọkunrin ti o fipa ba a lopọ ti yio si ma wa pẹlu rẹ titi ti yio fi ku ni? Ibeere miran ti enia tun gbọdọ beere ni eyi: ewo ni o da aabo bo awọn obirin julọ, iwa Al-Qur'an ti o muna ni tabi iṣesi Bibeli ti o dẹra?

Awọn kan, nipataki julọ ni Iwọ-Oorun,yio ṣọ lati fi gbogbo iṣaroye iṣọ iwa ọmọluwabi nitori aabo ṣe ẹlẹya. Ijiyan wọn ni wipe aabo ti o dara ju itan ẹkọ kalẹ, iwa ọlaju, ati ikara ẹni lọwọ ko.

Awa naa yio sọ wipe:
O dara bẹ ẹ ẹṣugbọn ko kun to. Ti 'ọlaju' ba to ni aabo, nigbanaa kini idi rẹ ti awọn obirin ni Ariwa America ko to ẹru ti o to darin ni opopona ti o ṣookun – tabi koda kakiri awọn ọgba-nla ti o pa ṣofo? Ti o ba jẹ ẹkọ nikan ni ọna-abayọ, nigbanaa kini idi ti o fi jẹ pe university ti wọn kakun julọ gẹgẹbi ti Queen fi ni 'walk home service' ti o wa fun awọn ọmọ-akẹkọbirin nikan ti inu ọgba?

Ti ikora ẹni lọwọko ba jẹ idahun si aabo, nigbanaa kini idi rẹ ti awọn ẹsun idanilagara ibalopọ ni ibi-iṣẹ ti wọn nroyin rẹ ni ori afẹfẹ ni ojoojumọ? Apejuwe kan ninu awọn ti wọn nfẹsun ibanilopọ ni tipatipa kan, ninu awọn ọdun diẹ ti o gbẹhin, ni: Awọn ọgagun oju omi, awọn ọga ile iṣẹ, awọn ọjọgbọn ile-ẹkọ giga, awọn igbimọ ilu, awọn adajọ ile-ẹjọ toga julọ, ati Olori orilẹ ede United States!

Emi fẹ le ma gba oju mi gbọ nigbati mo ka awọn iṣe onka ti o nbọ yi, ti wọn kọ sinu iwe pelebe ti Dean of Women's office ni Queen's University tẹ jade:

- Ni Canada, obirin kọọkan ni o ma nri ipalara ibalopọ ni gbogbo iṣẹju mẹfa mẹfa,
- Ikan ninu mẹta awọn obirin Canada ni yio ni ipalara abalopọ ni awọn igba kan ninu igbesi aiye wọn,

- Ikan ninu mẹrin awọn obirin ni o wa ni eti bebe ifipa balopọ tabi igbidanwo ifipa balopọ ni igbesi aiye rẹ,
- Ikan ninu mẹjọ ni wọn yio dalagara ibalopọ nigbati o ba wa ni College University, ati
- Iwadi fihan pe ọgọta ninu ọgọrun (60%) awọn ọkọkunrin ti ọjọ ori jẹ ti University ni Canada sọ pe awọn yio daran ifipa banilopọ ti awọn bani idaniloju pe wọn ko le ri awọn mu.

Ohunkan wa ti o jẹ aṣiṣe atipilẹwa ni awujọ ti a ngbe ninu rẹ. Ayipa tegbo-tigagaa ninu ọna iṣẹmi ati aṣa jẹ ohun kan ti o pọn dandan. Aṣa itiju jẹ ohun koṣe mani, wọntunwọnsin nibi imura, ninu ọrọ, ninu iwa awọn ọkunrin ati awọn obirin pẹlu. Laijẹbẹẹ, koro odiwọn yio ma pọ si koda bi ọjọ ṣe ngori ọjọ ni yio ma buru, eyiti o wa burujayi ni wipe awọn obirin nikan ni yio kẹsun rẹ. Ni tootọ, gbogbo wa ni a nri inira ṣugbọn gẹgẹbi K. Gibran ti sọ: *"...ẹniti o ngba agadu ko dabi ẹniti o nka".*[84] Nitorina, awujọ kan gẹgẹbi France ti o nle awọn ọmọdebirin kuro ni ile-ẹkọ nitori iwọṣọ wọn ni wọntunwọnsin, ni igbẹhin, ohun ni o nṣe ipalara fun ara rẹ.

O jẹ ọkan ninu awọn apara aiye ode oni wipe ibori ti wọn tọka si gẹgẹbi ami 'iwa mimọ' ti awọn obirin Alufaa ninu ijọ Aguda (Catholic) ba wọ nitori iṣe afihan ipo ọkunrin lori obirin, ni wọn wa fi ṣe ẹlẹya gẹgẹbi ami 'irẹjẹ' nigbati awọn obirin Musulumi ba wọ nitori aabo.

## APA 16 – ỌRỌ IPARI

Ibeere kanṣo ti gbogbo awọn ti ki nṣe Musulumi, ti wọn si ti ka akọsilẹ akọkọ nipa iwadi yi, ma nbeere ni: Njẹ awọn obirin Musulumi ni awujọ Musulumi loni ma nri itọju alapọnle ti wọn ṣe alaye rẹ nibiyi gba ? Ni eyiti o ṣeni laanu, idahun nipe: Rara.Niwọn igbati o jẹ wipe ibeere yi jẹ eyiti ko ṣe ma mu ẹnu ba ninu gbogbo ijiroro ti o ba ni ṣe pẹlu ipo awọn obirin ninu Islam, a gbọdọ ṣe alaye yekeyeke lori idahun yi ki a le fun akawe yi ni aworan ti o pe.

A gbọdọ ṣe alaye rẹ ni akọkọ wipe awọn iyapa ẹnu ti o gbilẹ ti o wa laarin awọn awujọ Musulumi ṣe ọpọlọpọ awọn ohun ti o wọpọ ni ohun ti o rọrun julọ.Oniranran ihuwa si awọn obirin ni o wa ni agbaiye Musulumi loni. Awọn iṣesi wọnyi yatọ ni awujọ kan si ekeji ati laarin ẹgbẹ kọọkan. Bioti lẹribẹ, eyiti o wọpọ jẹ ohun ti o fojuhan. O fẹ ẹ dabi wipe ọpọlọpọ awujọ Musulumi, fundikan tabi ekeji, ti yapa kuro nibi awọn apẹrẹ Islam nipa ika ipo awọn obirin si.Awọn iyapa kuro yi, ni eyi ti o pọ ju, wa ninu ọkan ninu awọn itọsọna ọtọọtọ meji ti o dojukọ ara wọn. Itọsọna akọkọ je eyi ti o mọniwọnba, ti o ni aala, ti o siba awọn aṣa mu, nigba ti ẹlẹẹkeji si jẹ eyi ti o lawọ daada ti wọn si gbe kalẹ ni ibamu si aṣa awọn ara iwọ-Oorun.

Awọn awujọ ti wọn ti ṣẹri kuro ni itọsọna alakọkọ ni o nhu iwa si awọn obirin ni ibamu si awọn aṣa ati ofin ti wọn jogun lọdọ awọn ti o ṣaju wọn. Awọn aṣa yi ni o jẹ pe o ma ngba ọpọlọpọ awọn ẹtọ ti Islam fun awọn obirin kuro lọwọ wọ. Lẹhinna, wọn ma nhu iwa si awọn obirin ni odiwọn ti o yatọ gedegede si eyi ti wọn ma nhu si awọn ọkunrin. Iṣe ẹlẹyamẹya yi ma nla igbe aiye eyikeyi ọmọbirin kọja: wọn ma npade rẹ pẹlu ayọ ti ko denu ni igbati wọn ba bi i ju ti ọmọkunrin; wọn ko ki nfẹ jẹ ki o lọ si ile-ẹkọ; wọn le kọdi nibi eyikeyi ipin rẹ ninu ogun ẹbi rẹ, o ma nwa ni abẹ abojuto nigbogbo igba ki o ma ba hu iwa alainitiju nigbati o jẹ wipe wọn fi aaye gba iwa alainitiju arakunrin rẹ, wọn le pa lori ohun ti o ṣe ti o si jẹ ohun ti awọn ọkunrin inu ẹbi rẹ ma fi nṣe faari nigbati wọn ba ṣe e; ọrọ diẹ ni o ni lati fi da sinu ọrọ ẹbi tabi ohun ti o jẹ anfani fun agbegbe, o le ma ni ikapa ti o peye lori ohun ini ati awọn ẹbun igbeyawo rẹ; ni ipari gẹgẹbi iya ohun funrarẹ yio yan lati bi ọmọkunrin ki o ba le ni ipo ti o gaju laari ẹgbẹ rẹ.

Ni ida keji, awọn awujọ Musulumi kan wa (tabi awọn ẹgbẹ kan ni awọn awujọ kan) ti aṣa ati ọna igbe aiye awọn ara Iwọ-Oorun ti gba aiye wọn kan. Awọn awujọ yi ni ọpọlọpọ igba ni wọn ma nkọṣe laironu nipa ohun ti wọn ba tẹwọ gba lati ọdọ awọn oyinbo (West) ni eyiti o jẹpe ni igbẹhin wọn ma nja awọn eso ibajẹ ọlaju awọn ara Iwọ-Oorun gba. Ni awọn awujọ yi, apẹẹrẹ ipo giga ni igbe aiye obirin isisiyi ni ima fi ẹṣọ ewa ara rẹ han. Nitorina, o ma nni akolekan gidi pẹlu aworan, iwọn ati iwuwo ara rẹ. O ma nṣe itọju ara rẹ ju ọkan rẹ lọ ati ẹwa rẹ ju ọgbọn rẹ lọ. Isapa rẹ lati rẹwa, fa ọkan, ṣojulọyin wulo ni awujọ yi ju awọn aṣeyọri ni ẹkọ, awọn ilepa ọgbọn,ati iru ẹgbẹ rẹ lọ. Ẹnikan ko lero wipe ohun le ri ẹda Al-Qur'an kan ninu apamọ rẹ (obirin) nigbati o jẹ wipe o ti kun fun awọn ohun aṣaraloge eleyi ti o ma nko kakiri gbogbo ibi ti o ba nlọ. Iwa-ẹmi rẹ koni aaye lawujọ ti iṣojulọyin rẹ ti gbaaye nibẹ. Nitorina, o le na igbesi aiye rẹ ni ilakaka lati mọ iwa abo rẹ ju imu inu-rere rẹ ṣẹ lọ.

Kini idi ti awọn awujọ Musulumi fi nyapa ilana Islam? Kosi idahun ti o rọrun. Alaye tokun rẹrẹ nipa awọn idi ti awọn Musulumi ko fi dunni mọ ilana Al kurani ni ibaṣe pẹlu awọn obirin kọja aye iwadi yi. A gbọdọ jẹ ki o fojuhan, sibẹsibẹ, wipe awọn awujọ Musulumi ti gunri kuro tipẹtipẹ nibi awọn ilana Islam ti o niṣe pẹlu ọpọlọpọ awọn ọrọ igbesi aiye wọn. Alafo ti o gboro ni o wa laarin ohun ti awọn Musulumi gbọdọ ni igbagbọ ninu rẹ ati ohun ti wọn nhu niwa. Alafo yi ko ki nṣe ohun iyanilẹnu titun.

O ti wa nibẹ fun ọpọlọpọ ọgọrun ọdun bi ọjọ si ṣe ngori ọjọ ni o ngboro si. Alafo gbigboro ti kosi iru rẹ yi ti ni abajade tolewu lori agbaiye Musulumi ti o si han ninu eyi ti o pọju ninu awọn ọrọ igbesi aiye wọn: oṣelu aninilara ati ajẹku, aiṣedede ọrọ-aje, aisotitọ larin ẹgbẹ, ipofo ọgbọn, ikaarẹ oye, etc. Ipo ti kin ṣe ti Islam ti awọn obirin ni awujọ Musulumi loni fẹ jẹ kiki apẹrẹ aisan. Iṣe eyikeyi atunṣe nipa ipo ti awọn obirin Musulumi wa loni, kosi ero wipe o le mu eso gidi jade ti ko ba ni awọn atunṣe igbe aiye awọn awujọ Musulumi ni apapọ ninu. Agbaiye Musulumi ni bukata si atunṣe ti yio gbe sunmọ awọn apẹrẹ ti o darajulọ ti Islam ti ko si ki nṣe wiwo lati okere. Ni akopọ, iro wipe ipo ti kodara ti awọn obirin Musulumi wa loni jẹ adiọkan buruku ti wọn wi jade.Awọn iṣoro awọn Musulumi lapapọ ko to eyi ti wọn lẹmọ Islam, awọn ni wọn sapa fifẹran ati jijinlẹ ijarawọn kuro lara rẹ.

Bakannaa, a tun gbọdọ fi rilẹ wipe idi pataki ti o wa labẹ iwadi alafiwe yi ko kin ṣe, ni eyikeyi ọna, lati ba ẹsin Juu tabi Kristiẹniti jẹ.
Ipo awọn obirin ninu aṣa atọwọdọwọ Juu-Kristiẹni loju awọn ọpagun ni sẹnturi ogun ti o gbẹhin le dabi ohun ifoya. Biolẹribẹ, a gbọdọ bojuwo laarin eyiti o sunmọ iwe itan ti o tọ. Ni gbolohun miran, eyikeyi iṣe ayewo nipa aaye awọn obirin ninu aṣa atọwọdọwọ Juu-Kristẹni gbọdọ jẹ pẹlu awọn iṣẹlẹ ti o rọ mọ itan ninu eyiti aṣa atọwọdọwọ yi ti jade. Kole si iye meji wipe awọn ero awọn Olukọni (Rabbis) ati awọn Baba ijọ nipa awọn obirin jẹ eyiti awọn ihuwa si awọn obirin eyiti o tan kalẹ ninu awọn awujọ wọn lapa. Bibeli tikalaarẹ jẹ eyiti awọn akọwe ọtọọtọ kọ ni awọn asiko ti o yatọ si ara wọn. Awọn akọwe yi o le mọ awọn riri ati ọna igbe aiye awọn enia ti o wa ni ayika wọn. Fun apejuwe, ofin agbere ti Majẹmu Lailai ṣe abosi fun awọn obirin ni eyiti wọn ṣe ipenija alaye ti o lọgbọn ni lakaye tiwa.

Ṣugbọn, ti a ba kiyesi ohun ti o daju wipe awọn iran Juu akọkọ ni ifẹ afẹju pẹlu ẹya ibi wọn ti wọn si nitara gidigidi lati da ara wọn ya sọtọ kuro lara awọn iran miran ti o yi wọn ka pẹlu wipe iba lopọ akọ ati abo ti ko mọ nipa awọn obirin ti o ti lọkọ ti awọn iran wọnyi nikan le ṣe idẹruba awọn irankan ayanfẹ yi, lẹhinnaa a wa le ni agbọye, ṣugbọn ko ki nṣe bi ti ibakẹdun pẹlu awọn idi fun irẹjẹ yi. Bakannaa, awọn iwa ẹlẹyamẹya ti awọn Baba ijọ ti o lodi si awọn obirin ko ṣe ya sọtọ lara ọgangan aṣa Greco-Roman eyiti wọn ngbe ninu rẹ. Koni ba oju mu lati ṣe agbeyẹwo asọsilẹ Juu-Kristiẹni laini ronu nipa ipo iwe itan ti ṣe pataki.

Ni ohun ti o daju, ini agbọye daradara nipa ipo iwe itan Juu-Kristiẹni o jẹ ohun ti o pọn dandan bakannaa fun agbọye ohun ti o lami ti awọn nkan ti Islam fi dasi itan aiye ati ọlaju eniyan. Ofin atọwọdọwọ Juu-Kristiẹni jẹ eyiti o ri ipalara ti irisi rẹ si tun yipada pẹlu awọn adugbo, awọn ipo, ati awọn aṣa eleyi o wa ninu rẹ. Nigbati o di ọgọrun ọdun ẹlẹẹkeje lẹhin iku Jesu, ilapa lara yi ti ko ayipada ti o kọja aala ba ojulowo ihin rere ti wọn ṣe iṣipaya rẹ fun Mose ati Jesu. Ipo alabuku ti awọn obirin wa ni agbaiye Juu-Kristiẹni nibi sẹnturi ẹlẹẹkeje jẹ ọkan ninu ohun ti a nsọ ọrọ nipa rẹ. Nitorinaa, ihin rere titun ti yio ṣe atọna awọn enia lọsi oju ọna ti o tọ jẹ ohun aigbọdọ mani. Al-Qur'an ṣapejuwe iṣẹ-pataki ti Ojiṣẹ titun wa ṣe gẹgẹbi itusilẹ fun awọn Juu ati awọn Kristiẹni kuro ninu awọn ẹru ajaga ti owa lori wọn:

*"Awọn na ni ẹniti nwọn tẹle ti Ojiṣẹ na, Annabi na, ẹniti ko mọ ọ kọ ti ko mọ ọ ka ẹniti nwọn ba akọsilẹ nipa rẹ lọdọ wọn ninu At-Taorata ati ninu Injila, yio ma foro wọn si iwa rere yio si ma kọ buburu fun wọn, yio si ma ṣe awọn ohun ti ko dara ni ewọ fun wọn, yio sa ma gbe awọn ẹru ti wuwo kuro fun wọn ati ajaga ti mbẹ fun wọn"* **(Qur'an 7:175)**.

Nitorinaa, a ko gbọdọ bojuwo Islam gẹgẹbi ofin orogun si ofin ẹsin Juu tabi ofin ẹsin Kristiẹniti. A gbọdọ kiyesi gẹgẹbi eyiti o ko gbogbo ihin rere ti wọn ti ṣe iṣipaya rẹ ṣiwaju ki ohun (ihin rere Islam) to de sinu, ni pepe ati ni ailabuku.

Ni ipari iwadi yi, yio dun mọmi ninu lati gba awọn ara ilu Musulumi aiye ni imọran ti o nbọ yi. Ọgọọrọ awọn obirin Musulumi ni wọn ti fi awọn ẹtọ ti Islam fun wọn dun wọn lati igba ti o ti pẹ. Agbọdọ wa atunṣe si awọn aṣiṣe awọn ẹni iṣaju. Lati ṣe eleyi ko nṣe fun anfaani ẹnikan, bi ki nṣe wipe ojuṣe ni o jẹ ti wọn si ṣe ni ọranyan le gbogbo awọn Musulumi lori. Awujọ Musulumi kakiri agbanla aiye gbọdọ ṣe agbekalẹ iwe-aṣẹ awọn ẹtọ ti o jẹ ti awọn obirin Musulumi eyiti o jẹ lati inu awọn ẹkọ Al-Qur'an ati awọn ilana Anabi Islam. Iwe-aṣẹ yi gbọdọ fun awọn obirin Musulumi ni gbogbo ẹtọ ti Ẹlẹda fun wọn. Nigbanaa, a gbọdọ ṣe agbekalẹ gbogbo ohun koṣe mani si aaye rẹ ki iwe-aṣẹ ba le di amuṣẹ ni bi o titọ ati bi o ti yẹ. O ti yẹ ki iwe-aṣẹ yi tiwa tipẹ, ṣugbọn o dara ki o pẹ ju ki o ma si rara lọ. Ti awọn Musulumi kakiri agbanla aiye ko ba le ṣe onigbọwọ fun iwe-aṣẹ awọn ẹtọ ti Islam fun awọn iya, awọn iyawo, awọn arabirin, awọn ọmọbirin wọn, tawani o le ṣe?

Siwajusi, igboya lati koju doju ija kọ awọn ohun ti a ti ṣe kọja, ati lati kọ gbogbo awọn aṣa atọwọdọwọ ati awọn iṣe ti awọn babanla wa silẹ ni gbogbo igba ti wọn ba ntako awọn ilana Islam. Njẹ Al-Qur'an ko ṣofintoto awọn keferi Larubawa lori titọ awọn aṣa awọn babanla wọn lẹhin pẹlu ifoju? Ni ẹgbẹ miran, a gbọdọ gbe igbesẹ ti o lagbara nipa eyikeyi ohun ti a ba ṣe atẹwọda rẹ lati Iwọ-Oorun tabi inu eyikeyi aṣa miran. Ibaṣepọ pẹlu ati ikọ ninu awọn aṣa miran jẹ iriri ti koṣe da iyele. Al-Quran kiyesi abaṣepọ yi gẹgẹbi ọkan ninu awọn ero ẹda:

*"Ẹnyin enia, dajudaju A da nyin lati ara ọkunrin ati obirin, A si ṣe nyin ni orilẹ ede ati iran-iran ki ẹ le baa maa mọ ara nyin"* **(Qur'an 49:13)**. Bẹẹ loṣe ri laisọ, ṣugbọn, wipe ikọṣe awọn kan ifọju jẹ apẹrẹ gidi ti ohun ti a wi jade lairo tara ẹni.

Oluka ti ko ki nṣe Musulumi, Juu, Kristiẹni tabi bibẹẹkọ, ni mo ṣe agbekalẹ awọn ọrọ igbẹhin yi fun. O nruni loju kini idi ti ẹsin ti o jẹ wipe ohun ni o ṣe irapada ipo awọn obirin fi wa di eyiti wọn ya sọtọ ni eyiti o fi ntẹ ẹtọ awọn obirin mọlẹ ju. Iro yi nipa Islam jẹ ọkan ninu awọn adaparọ ti wọn tan kakiri aiye loni. Adaparọ yi jẹ nkan ti awọn iwe imọ, awọn akọsilẹ kan, ati awọn aworan ti nri ti Hollywood pilẹ rẹ. Abajade ti ko ṣe yẹsilẹ ti awọn aworan amunibini aṣini lọna wọnyi jẹ eyiti awọn enia ṣi gbọye ti wọn si nbẹru eyikeyi ohun ti o ba rọmọ Islam. Iṣe afihan aworan odi eyiti ko ribẹ nipa Islam ninu irohin tabi lori afẹfẹ gbọdọ de opin ti a ba fẹ ṣẹmi ninu aiye ti o la kuro ninu awọn apẹrẹ ẹlẹya-mẹya, ẹta-inu ati ede-aiyede. Awọn ti ko ki nṣe Musulumi gbọdọ mọ wipe alafo ti o gboro wa laarin igbagbọ awọn Musulumi ati awọn iwa wọn atipe ohun ti o daju gan-an ni wipe awọn iwa awọn Musulumi kọ ni o pọn dandan lati ṣoju Islam. Isami si ipo awọn obirin lawujọ ni agbaiye Musulumi loni gẹgẹbi *"iwa Islam"* jẹ eyiti o jina ododo si bi wọn ṣe nsami si ipo awọn obirin ni Iwọ-Oorun loni gẹgẹbi *"iwa Juu-Kristiẹni"*. Ini agbọye bayi ninu ọkan, awọn Musulumi ati awọn ti ko ki nṣe Musulumi gbọdọ bẹrẹ ọna ibaraẹni sọrọ ati ijiroro lati le yọ awọn iro-aburu, awọn ifura, ati awọn ibẹrubojo kuro. Igbe aiye irọrun ọmọ enia ni ọjọ iwaju ni o nṣe iru ijiroro bayi ni ọranyan.

Agbọdọ ri Islam gẹgẹbi ẹsin ti o ṣe atunṣe pupọ nipa ipo awọn obirin lawujọ ti o si jinki wọn ni ọpọlọpọ awọn ẹtọ eyiti aiye ode oni ṣẹṣẹ mọ ọ fun obirin ninu senturi ọdun ti a wa ninu rẹ yi nikan. Islam ṣi ọpọlọpọ nkan lati ṣe fun obirin ode-oni: iyi, apọnle, ati aabo ni gbogbo aaye ati gbogbo ipo igbe aiye rẹ lati igba iwaiye titi ti yio fi ku ni afikun si ikasi, dọgbadọgba, ati awọn ọna fun imuṣẹ gbogbo awọn ohun ẹmi, ọgbọn, adamọ, ati awọn ẹdun ọranyan rẹ. Idi abajọ re, eyiti o pọju ninu awọn ti wọn yan laayo lati di Musulumi ni orilẹ ede bi Britain obirin ni wọn jẹ. Ni U.S. onka awọn obirin ti ọkan wọn nyi pada si Islam jẹ ilọpo ilọpo onka ọkunrin ni 4 si 1.[85]

Islam ni ọpọlọpọ lati ṣe fun aiye wa eleyi ti o jẹ ohun aigbọdọ mani nla fun itọsọna iwa ati ṣiṣe olori. Ambassador Herman Eilts, ninu ijẹri kan ni iwaju igbimọ nipa foreign Affairs ti Ile Awọn Aṣoju ti Ile Igbomọ Aṣofin U.S. ni June 24th, 1985, sọ wipe: *"Awọn Musulumi agbaiye loni ti sunmọ ẹgbaagbeje kan. Eyi si jẹ apẹrẹ ti o wọni lọkan. Ṣugbọn ohun ti o tun wọmi lọkan ni wipe Islam nikan ni ẹsin kanṣoṣo ti o nyara gboro. Eleyi jẹ ohun ti a gbọdọ kiyesi. Ohun kan jẹ otitọ nipa Islam. O ma nfa ọpọlọpọ awọn ẹni-rere lọkan".*

Bẹẹni, ohun kan jẹ otitọ nipa Islam o si ti wa to akoko lati wa ohun yẹn jade. Emi ni ero wipe iwadi yi jẹ igbesẹ kan lori agbọnri yi.

# ỌRỌ ETI BEBE


1. The Globe and Mail, Oct. 4, 1994.
2. Leonard J. Swidler, Women in Judaism: the Status of Women in Formative Judaism (Metuchen, N.J: Scarecrow Press, 1976) p. 115.
3. Thena Kendath, "Memories of an Orthodox youth" in Susannah Heschel, ed. On being a Jewish Feminist (New York: Schocken Books, 1983) pp.96-97.
4. Swidler, op. cit., pp. 80-81.
5. Rosemary R. Ruether, "Christianity", in Arvind Sharma, ed., Women in World Religions (Albany: State University of New York Press, 1987) p. 209.
6. For all the sayings of the prominent Saints, see Karen Armstrong, The Gospel According to Woman (London: Elm Tree Books, 1986) pp. 52-62. See also Nancy van Vuuren, The Subversion of Women as Practiced by Churches, Witch-Hunters, and Other Sexists (Philadephia: Westminister Press) pp. 28-30.
7. Swidler, op. cit., p. 140.
8. Denise L. Carmody, "Judaim", in Arvind Sharma, ed., op. cit., p. 197.
9. Swidler, op. cit., p. 137
10. Ibid., p. 138.
11. Sally Priesand, Judaism and the New Woman (New York: Behrman House, Inc., 1975) p.24.
12. Swidler, op. cit., p. 115.
13. Lesley Hazleton, Israeli Women The Reality Behind the Myths (New York: Simon and Schuster, 1977) p. 41
14. Gage, op. cit. p. 142
15. Jeffrey H. Togay, "Adultery", Encyclopaedia Judaica, Vol. II, col. 313. Also, see Judith Plaskow, Standing Again at Sinai: Judaism from a Feminist Perspective (New York: Harper & Row Publishers, 1990) pp.170-177.
16. Hazleton, op. cit., pp. 41-42.
17. Swidler, op. cit., p. 141.
18. Matilda J. Gage, Woman, Church, and State (New York: Truth Seeker Company, 1893) p. 141
19. Louis M. Epstein, The Jewish Marriage Contract (New York: Arno Press, 1973) p. 149.
20. Swidler, op. cit., p. 142.
21. Epstein, op. cit., pp 164-165.
22. Ibid., pp. 112-113. See also Priesand, op. cit., p. 15.
23. James A. Brundage, Law, Sex, and Christian Society in Medieval Europe (Chicago: University of Chicago Press, 1987) p. 88.
24. Ibid., p. 480.
25. R. Thompson, Women in Stuart England and America (London: Routledge & Kegan Paul, 1974) p. 162.
26. Mary Murray, The Law of the Father (London: Routledge, 1995) p. 69.

27. Gage, op. cit., p. 143.
28. For example, see Jeffrey Lang, Struggling to Surrender, (Beltsville, MD: Amana Publications, 1994) p. 167.
29. Elsayyed Sabiq, Fiqh al Sunnah (Cairo: Darul Fatah lile'lam Al-Arabi, 11th edition, 1994), vol. 2, pp. 218-229.
30. Abdel-Haleem Abu Shuqqa, Tahreer al Mar'aa fi Asr al Risala (Kuwait: Dar al Qalam, 1990) pp. 109-112.
31. Leila Badawi, "Islam" in Jean Holm and John Bowker, ed., Women in Religion (London: Pinter Publishers, 1994) p. 102.
32. Amir H. Siddiqi, Studies in Islamic History (Karachi: Jamiyatul Falah Publications, 3rd edition, 1969) p. 138.
33. Epistein, op. cit., p. 196.
34. Swidler, op. cit., pp. 162-163.
35. The Toronto Star, Apr. 8, 1995.
36. Sabiq, op. cit., pp. 318-329. See also Muhammad al Ghazali, Qadaya al Mar'aa bin al Taqaleed al Rakida wal Wafida (Cairo: Dar al Shorooq, 4th edition, 1992) pp. 178-180.
37. Ibid., pp. 313-318.
38. David W. Amram, The Jewish Law of Divorce According to Bible and Talmud (Philadelphia: Edward Stern & CO., Inc., 1896) pp. 125-126.
39. Epistein, op. cit., p. 219.
40. Ibid., pp. 156-157.
41. Muhammad Abu Zahra, Usbu al Fiqh al Islami (Cairo: al Majlis al A'la li Ri'ayat Funun, 1963) p. 66.
42. Epistein, op. cit., p. 122.
43. Armstrong, op. cit., p. 8.
44. Epistein, op. cit., p. 175.
45. Ibid., p. 121
46. Gage, op.cit., p. 142.
47. B. Aisha Lemu and Fatima Heeren, Woman in Islam (London: Islamic Foundation, 1978) p. 23.
48. Hazleton, op. cit., pp. 45-46.
49. Ibid., p. 47.
50. Ibid., p. 49.
51. Swidler, op. cit., pp. 144-148.
52. Hazleton, op. cit., pp. 44-45.
53. Eugene Hillman, Polygamy Reconsidered: African Plural Marriage and the Christian Churches (New York: Orbis Books, 1975) p. 140.
54. Ibid., p. 17.
55. Ibid., pp. 88-93.
56. Ibid., pp. 92-97.
57. Philip L. Kilbride, Plural Marriage For Our Times (Westport, Conn.: Bergin & Garvey, 1994) pp. 108-109.
58. The Weekly Review, Aug. 1, 1987.
59. Kilbride, op. cit., p. 126.

60. John D’Emilio and Estelle B. Freedman, Intimae Matters: A history of Sexual in America (New York: Harper & Row Publishers, 1988) p.87.
61. Ute Frevert, Women in German History: from Bourgeois Emancipation to Sexual Liberation (New York: Berg Publishers, 1988) pp. 263-264.
62. Ibid., pp. 257-258.
63. Sabiq, op. cit., p. 191.
64. Hillman, op. cit., p. 12.
65. Nathan Hare and Julie Hare, ed ., Crisis in Black Sexual Politics (San Francisco: Black Think, 1989) p. 25.
66. Ibid., p. 26.
67. Kilbride, op. cit., p. 94.
68. Ibid., p. 95.
69. Ibid.
70. Ibid., pp. 95-99.
71. Ibid., p. 118.
72. Lang, op. cit., 172.
73. Kilbride, op. cit., 72-73.
74. Sabiq, op. ci., pp. 187-188.
75. Abdul Rahman Doi, Woman in Shari’ah (London: Ta-Ha Publishers, 1994) p. 76.
76. Menachem M. Brayer, The Jewish Woman in Rabbinic Literature: A Psychosocial Perspective (Hoboken, N.J: Ktav Publishing House, 1986) p. 239.
77. Ibid., pp. 316-317. Also see Swidler, op. cit., pp. 121-123.
78. Ibid., p. 139.
79. Susan W. Schneider, Jewish and Female (New York: Simon & Schuster, 1984) p. 237.
80. Ibid., pp. 238-239.
81. Alexandra Wright, “Judaism”, in Holm and Bowker, ed., op. cit., pp. 128-129.
82. Clara M. Henning, “Cannon Law and the Battle of the Sexes” in Rosemary R. Reuther, ed., Religion and Sexism: Images of Woman in the Jewish and Christian Traditions (New York: Simon & Schuster, 1974) p. 272.
83. Donald B. Kraybill, The riddle of the Amish Culture (Baltimore: Johns Hopkins University Press, 1989) p. 56.
84. Khalil Gibran, Thoughts and Meditations (New York: Bantam Books, 1960) p. 28.
85. The Times, Nov. 18, 1993.

www.islamic-invitation.com